




# OKÒWÒ RẸ, ỌJỌ-ỌLA RẸ

**Ìtọsọnà Ìpìlẹ sí Dídá Okòwò sílẹ fún Àwọn Aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn tó jẹ Olùdókòwò**






# Ìmọríri

**Ìtọ́sọ́nà yìí wá látọwọ́ Àjọ Àwọn Aṣíwá-láti ìlú ibòmíràn ni New York àti Ilé-iṣẹ́ Pratt fún Ìdàgbàsókè Àwùjọ Ènìyàn, gẹ́gẹ́ bí ara ìgbìyànjú láti mú rírááyèsí àlàyé tó yéni yékéyéké àti àwọn ohun àmúlò fún àwọn aṣíwá-láti ìlú ibòmíràn tó jẹ́ olùdókòwò ní New York gbèrú síi. Títẹ̀jáde ìtọ́sọ́nà yìí wá látọwọ́ Ilé-iṣẹ́ Capital One, Ẹ̀ka Ìdàgbàsókè Àwọn Ọ̀dọ́ ati Àwùjọ Ènìyàn ní New York, Ilé-iṣẹ́ Ìjọba Ìbílẹ̀ ni New York àti Ọ́fíìsì Agbẹnusọ, nípasẹ̀ Kọ́kọ́rọ́ sí Ìṣàgbéjáde Ohun Tuntun ti Àjọ Àwọn Aṣíwá-láti ìlú ibòmíràn ni New York.**

---

Àtẹ̀jádé Oṣù Kẹrin Ọdún 2019

Àrà àwòrán látọwọ́ Ben Dodd, pẹ̀lú àtìlẹ́yìn látọwọ́ Sydney Céspedes, Sal Muñoz

Àwọn Ìfihàn látọwọ́ June Lee

## Àjọ Àwọn Aṣíwá-láti ìlú ibòmíràn ni New York

Àjọ Àwọn Aṣíwá-láti ìlú ibòmíràn ni New York jẹ́ àjọ tí kò sí fún ìpawówọlé tó ní àlá ọjọ́ iwájú láti rí ìpínlẹ̀ New York tó lágbára síi nítorí gbogbo ènìyàn ni a gbà wọlé, ni a hùwà sí láìsí ojúsàájú, ni a sì fún ní àǹfàní láti tẹ̀lé àlá ọjọ́-ọ̀la wọn. Àjọ náà a máa mú ìṣọ̀kan wà laarin àwọn aṣíwá-láti ìlú ibòmíràn, àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ àti ojúlùmọ̀ kí gbogbo àwọn ara New York lápapọ̀ lè máa gbèrú síi.

## Ilé-iṣẹ́ Pratt fún Ìdàgbàsókè Àwùjọ Ènìyàn

Ilé-iṣẹ́ Pratt fún Ìdàgbàsókè Àwùjọ Ènìyàn da ìṣètò ìlú ńlá pọ̀ mọ́ ìṣèwádìí, ìgbẹnusọ fún ìlànà tó tọ́, àti ìṣèrànlọ́wọ́ fún àwọn okòwò kékèké láti fún àwọn àwùjọ tó kún fún àwọn tí owó tó ń wọlé fún wọn kéré tàbí tó mọ níwọ̀nba ní agbára láti lè ṣètò ọjọ́-ọ̀la wọn, àti kí wọ́n sì lè múu ṣẹ, fún ìlú New York tó mú gbogbo ènìyàn dọ́gbà, tí wọ́n sì lè ṣètọ́jú ara wọn.

# TÁBÌLÌ ÀKÓÓNÚ

Ò ń bẹ̀rẹ̀ Okòwò bí? Àwọn ohun tó yẹ kí o mọ̀! ..... 6

Bí a ṣe ńlo ìtọ́sọ́nà yìí ..... 6

Bíbẹ̀rẹ̀ ..... 7

Àwọn Ìmọ̀ràn fún Yíyan Ìlànà Àgbékalẹ̀ Okòwò ..... 11

Àwọn Ìlànà Àgbékalẹ̀ Okòwò 6 tó wà ..... 15

Okòwò Àdánìkanni ..... 16

Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Gbogbogbò ..... 17

Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba ..... 19

Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba (LLC) ..... 21

Ilé-iṣẹ́ Ńlá ..... 23

Aláјẹṣẹ́kù Ọ̀ṣìṣẹ́ ..... 26

Ìṣètumọ̀ ..... 27

Àwọn Ìwé-àkọsílẹ̀ Pàtàkì ..... 28

Àwọn Ohun Àmúlò ..... 29

# Àkọ́ráńṣẹ́ Kan látọ̀dọ̀ Agbẹnusọ Ìgbìmọ̀ Ìlú New York Corey Johnson


Ẹ̀yin Ará New York Mi Ọ̀wọ́n,

Ìlú New York tí a mọ̀, tí a sì fẹ́ràn kí yóò jẹ́ ohunkóhun láìsí àwọn olùdókòwò wa tó ṣí wá láti ìlú mìíràn. Àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ni ó jẹ́ egungun ẹ̀yìn ọrọ̀-ajé agbègbè wa, pẹ̀lú àkójọpọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ àti okòwò níní tí ipele rẹ̀ ga. Ní tòótọ́, àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ni ó ni ìdajì àwọn okòwò tó wà ní New York, èyí sì fi bílíọ̀nù $228 kún àkójọpọ̀ iye owó gbogbo ọjà àti ìpèsè iṣẹ́ lápapọ̀ ní ìlú yìí ní ọdún 2017. Ṣùgbọ́n, àwọn ohun àmúlò kan wà tí a yàsọ́tọ̀ pàtó fún ríran àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn tó ń gbèrò àti jẹ́ olùdókòwò lọ́wọ́. Inú mi dùn láti fi ohun àmúlò yìí kún àpótí-iṣẹ́ ìgbìyànjú Ìlú láti ṣàtìlẹ́yìn fún abala àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn tó ní okòwò, àwọn èyí tó ń gbèrú síi. Ó jẹ́ ìgbésẹ̀ pàtàkì ní mímúu dánilójú pé àwa ń tẹ̀síwájú láti máa mú àwọn ìdènà sí àṣeyọrí kúrò lọ́nà fún gbogbo àwọn ará New York.

Ní àsìkò tó jẹ́ pé ìjọba àpapọ̀ ń dojú ìjà kọ àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ará New York tó ń ṣiṣẹ́ takuntakun, ó jẹ́ ohun ìdùnnú fún mi pé Ìgbìmọ̀ Ìlú fọwọ́sí ṣíṣàgbéjáde ìtọ́sọ́nà yìí. “Okòwò Rẹ, Ọjọ́-ọ̀la Rẹ” jẹ́ àṣeparí ìjíròrò tó lágbára pẹ̀lú àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ amòfin ìṣílọ-láti-ìlú-kan-sí-òmíràn, ìdókòwò, àti owó-ìlú, àti pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ́ àti olùdókòwò tó ń bá àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ṣiṣẹ́. Lọ́nà tó pọ̀ lóríṣiríṣi, ó jẹ́ àkọ́kọ́ irú rẹ̀. Ìtọ́sọ́nà yìí pèsè ètò ìgbésẹ̀ tó yéni yékéyéké pẹ̀lú àlàyé tó lè rannilọ́wọ́ fún gbogbo àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ní New York tó nífẹ̀ẹ́sí ṣíṣí okòwò, ṣùgbọ́n tí wọn kò ní ìdánilójú nípa ìgbésẹ̀ tó yẹ kí wọ́n gbé tàbí irú okòwò tó yẹ kí wọ́n ṣí pàápàá.

Ìtọ́sọ́nà yìí kìí ṣe irinṣẹ́ pàtàkì nìkan fún àwọn ará ìlú New York, ṣùgbọ́n títẹ̀jáde rẹ̀ lásìkò yìí tún ṣàfiránṣẹ́ ohun tó ṣe pàtàkì látọ̀dọ̀ Ìgbìmọ̀ náà pé a gba àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ará New York wọlé tọwọ́tẹsẹ̀ síbí, àti pé a mọ rírì àwọn akitiyan ńlá wọn sí Ìlú náà. Ìrètí mi ni pé ìtọ́sọ́nà yìí yóò fún gbogbo àwọn ará New York ní ìwúrí láti lè gbé ìgbésẹ̀ náà tó kàn báyìí!

Tiyín nínú iṣẹ́,



Agbẹnusọ Ìgbìmọ̀ Ìlú New York
Corey Johnson


# Àkọráńṣẹ́ Kan látọ̀dọ̀ Àwọn Olùdarí Apàṣẹ

Fún iye ọdún tó ju 150 lọ, New York ti jẹ́ orísun àǹfàní fún àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn. Àwọn náà sì ń tẹ̀síwájú láti máa mú ọrọ̀-ajé rẹ̀ lágbára síi. Àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn jẹ́ bíi ìdámẹ́rin àwọn òṣìṣẹ́ ní New York, wọ́n sì ń mú iye owó tó tó ọ̀pọ̀ bìlíọ̀nù dọ́là wọlé sára owó tó ń wọlé ní agbègbè náà. Ṣùgbọ́n àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn kò kàn kí ń darí iye òṣìṣẹ́ tó wà ní New York nìkan, àwọn gan-an ni wọ́n ń sọ bí ohun gbogbo ṣe ń lọ sí: Iye olùdókòwò tó ju 83,000 lọ ní New York ló jẹ́ aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn, èyí tó mú wọn jẹ́ iye ènìyàn tó pọ̀ jùlọ tó ni àwọn okòwò kékèké.

Ó jẹ́ ohun tó dùn mọ́ Àjọ Àwọn Aṣíwá-láti ìlú ibòmíràn ni New York àti Ilé-iṣẹ́ Pratt fún Ìdàgbàsókè Àwùjọ Ènìyàn nínú láti pèsè ìtọ́sọ́nà yìí gẹ́gẹ́ bí ohun àmúlò tó ṣeé na ọwọ́ mú láti ran àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn lọ́wọ́ láti bẹ̀rẹ̀ àti láti tẹ̀síwájú nínú ṣíṣòwò tó ní àṣeyọrí. Ọ̀pọ̀ àwọn ẹgbẹ́, ibùdó ìṣèrànwọ́ fún okòwò tuntun, àwọn ìpèsè iṣẹ́ fún àwọn okòwò kékèké, àti àwọn olùpèsè ìrànlọ́wọ́ lábẹ́ òfin ni ó wà láwùjọ tí wọ́n ń pèsè àwọn iṣẹ́ tó ṣe pàtàkì fún àwọn olùdókòwò, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀ àwọn wọ̀nyí ni ó wà ní èdè tí ọ̀pọ̀ ènìyàn kò lè lò. Èyí jẹ́ ohun ìṣòro kan fún gbogbo àwọn olùdókòwò ṣùgbọ́n ní pàtàkì fún àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn bí a bá ronú nípa àwọn ìdènà èdè àti àṣà tí wọ́n máa ń dojúkọ.

Ìtọ́sọ́nà yìí bẹ̀rẹ̀ sí ní wá ojúùtú sí díẹ̀ lára àwọn ìdènà kan pàtó ti àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn máa ń dojúkọ nipasẹ̀ pípèsè àlàyé tó ṣí sílẹ̀ ní àwọn oríṣiríṣi èdè. Ohun àmúlò akọ́nilẹ́ẹ̀kọ́ yìí yóò ran àwọn aláàbáṣiṣẹ́pọ̀ àwùjọ tó wà nílẹ̀ fún iṣẹ́ lọ́wọ́ láti pèsè àwọn iṣẹ́ àtìlẹ́yìn okòwò tó ṣe kókó fún àwùjọ àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn. Ṣíṣe àtìlẹ́yìn fún ìdókòwò àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn àti àwọn iṣẹ́ tí wọ́n ń dásílẹ̀ ṣe pàtàkì fún ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé New York lápapọ̀, yóò sí mú kí àwọn àǹfàní tó pọ̀ síi ṣí sílẹ̀ fún gbogbo àwọn ará ìlú New York.


Nítòótọ́,



Steve Choi

Olùdarí Apàṣẹ

Àjọ Àwọn Aṣíwá-láti ìlú ibòmíràn ni New York



Adam Friedman

Olùdarí Apàṣẹ

Ilé-iṣẹ́ Pratt fún Ìdàgbàsókè Àwùjọ Ènìyàn

# Ò Ń BẸ̀RẸ̀ OKÒWÒ BÍ? ÀWỌN OHUN TÓ YẸ KÍ O MỌ̀!

## Bí a Ṣe Ńlo Ìtọ́sọ́nà yìí

Ìdókòwò àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ni ó jẹ́ egungun ẹ̀yìn ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè yìí. Ní Ìpínlẹ̀ New York, àwọn olùdókòwò tó jẹ́ aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ni ó jẹ́ 33.8% àwọn olùgbé tó ń ṣiṣẹ́ aláàdáni, ti wọ́n sì ń mú iye owó tó tó bílíọ̀nù $7.2 wọlé nípasẹ̀ okòwò.[1] Bí ó ti jẹ́ pé ó ṣeé ṣe ní ìlọ́po méjì fún àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn láti bẹ̀rẹ̀ okòwò ju àwọn ọmọ-ìlú tí a bí ni U.S. lọ, àwọn ohun àmúlò díẹ̀ kan wà tí a yàṣọ́tọ̀ pàtó láti ran àwọn olùdókòwò aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn lọ́wọ́.[2]

**A ṣe ìtọ́sọ́nà yìí fún gbogbo àwọn olùdókòwò aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ní báyìí àti àwọn tó ń gbìyànjú àti jẹ́ ọ̀kan, láì ka ipò ìṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn wọn sí, láti ràn wọ́n lọ́wọ́ láti ní òye àwọn àṣàyàn tó wà fún bíbẹ̀rẹ̀ àti mímú okòwò ara wọn ṣiṣẹ́ ní Ìpínlẹ̀ New York.** A ṣe ìtọ́sọ́nà yìí gẹ́gẹ́ bíi àtúnyẹ̀wò lápapọ̀, ó sì ní àwọn àlàyé tí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti pinnu irú ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò tó tọ́ fún ọ láti ṣe, àwọn ohun tí o nílò láti dá okòwò tìrẹ sílẹ̀, àti àwọn owó àti owó-ìlú tí o gbọ́dọ̀ retí láti san kí okòwò rẹ báa lè wà ní ṣíṣí fún iṣẹ́.

Ìtọ́sọ́nà yìí kò sọ nípa àwọn ohun tí o nílò kan gẹ́gẹ́ bíi ìwé-àṣẹ tàbí ìgbaniláàyè tí o lè nílò fún oríṣi okòwò ìṣàgbéjáde tàbí ìkọ́ṣẹ́mọṣẹ́ kan pàtó. **Ìtọ́sọ́nà yìí kò pèsè àmọ̀ràn nípa òfin tàbí sísan owó-ìlú.** A gba àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn olùdókòwò níyànjú púpọ̀ láti wá ìmọ̀ràn òfin nípa ìṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn tí ara wọn, okòwò wọn, tàbí àwọn owó-ìlú tí wọ́n nílò láti san àti àwọn tí wọn kò nílò láti san. Fún àlàyé síwájú síi, kàn sí abala àwọn ohun àmúlò nínú ìtọ́sọ́nà yìí. Àlàyé tó wà nínú ìtọ́sọ́nà yìí jẹ́ tuntun jùlọ ní oṣù Kẹwàá ọdún 2018, a kì yóò sì múu dójú ìwọ̀n mọ́.

1. "Àwọn Aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ní New York." (Ọjọ́ 4, osù Kẹwàá, ọdún 2017) Ìgbìmọ̀ Ìṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ti Amẹ́ríkà. www.americanimmigrationcouncil.org/research/immigrants-in-new-york
2. "Ipò Ọrọ̀-ajé fún Gbígba Àwọn Àṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn Olùdókòwò Wọlé." (Ọjọ́ 8, oṣù Kẹsàn-án, ọdún 2015) Kauffman Foundation. www.kauffman.org/what-we-do/resources/entrepreneurship-policy-digest/the-economic-case-for-welcoming-immigrant-entrepreneurs

# Bíbẹ̀rẹ̀

## Agbaṣẹ́ṣẹ olómìnira ní àfiwé pẹ̀lú Òṣìṣẹ́? (àti ìdí tó fi ṣe pàtàkì)

Ọ̀pọ̀ àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn a máa kojú ìdènà ní wíwá iṣẹ́ tó ń sanwó tó dára ní United States. Níni okòwò lè pèsè àǹfàní àti tẹ̀síwájú bí a bá ń ronú nípa ọrọ̀-ajé fún àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn. Ní pàtó, bí a kò bá fún ọ ní àṣẹ láti ṣiṣẹ́ ní U.S. gẹ́gẹ́ bí òṣìṣẹ́, bíbẹ̀rẹ̀ okòwò tìrẹ lè ràn ọ́ lọ́wọ́ láti wá jíjẹ-mímu.

Ó jẹ́ ohun tó lòdì sí òfin fún agbanisíṣẹ́ kan láti gba ẹnití wọ́n mọ̀ pé a kò fún láṣẹ láti ṣiṣẹ́ ni United States sí iṣẹ́. Gbogbo agbanisíṣẹ́ ni ó ní ojúṣe láti ṣàyẹ̀wò pé ẹni yòówù tí wọ́n gbàsíṣẹ́ ní àṣẹ láti ṣiṣẹ́, nípa:

- Kíkọ ohun tó yẹ sínú Fọ́ọ̀mù I-9
- Ṣíṣàyẹ̀wò àwọn ohun ìdánimọ̀ òṣìṣẹ́ (bíi nọ́mbà ààbò àwùjọ, káàdì gíríìnì, ìwé ìdánimọ̀ fún ìrìn-àjò, abbl.)

Kò sí òfin ìjọba àpapọ̀ tàbi ti Ìpínlẹ̀ New York kan pàtó tó dènà aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn kan tí kò ní àṣẹ láti ṣiṣẹ́ láti má lè ní okòwò, tàbí láti má lè jẹ́ olùdókòwò araẹni. Olùdókòwò to dá iṣẹ́ sílẹ̀ fúnraarẹ̀ ni a máa ń pé nígbà mìíràn ní “agbaṣẹ́ṣẹ olómìnira.” A kìí sábà ní kí àwọn agbaṣẹ́ṣẹ olómìnira kọ àkọyé sínú Fọ́ọ̀mù I-9 fún àwọn oníbàárà wọn nígbàtí wọ́n bá bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ àgbàṣe tuntun. Bí o bá dá okòwò sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin bí a ṣe ṣàlàyé nínú ìtọ́sọ́nà yìí, ohun to dádúró lábẹ́ òfin náà lè ṣòwò, èyí tó kan pípèsè ọjà àti iṣẹ́, àti gbígba iṣẹ́ àgbàṣe.

Gẹ́gẹ́ bí ohun tó ṣeé ṣe, ọ̀pọ̀ àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn máa ń lè wà ọ̀nà àti-jẹ-àti-mu wọn nípa bíbẹ̀rẹ̀ okòwò kan lái ka ipò ìṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn wọn sí. Ó ṣe pàtàkì pé gẹ́gẹ́bi olùdókòwò, o tẹ̀lé àwọn òfin tó kan mímú okòwò rẹ ṣiṣẹ́, èyí tó kan sísan owó-ìlú. Ó tún gbọ́dọ̀ yé ọ pé bíbẹ̀rẹ̀ okòwò nílò fífàkalẹ̀ àwọn ìwé kan sọ́dọ̀ àwọn aláṣẹ ìjọba àti àwọn ilé-ìfowópamọ́, kò ní kí a má dá ọ padà sí ìlú tí o ti wá kúrò ní U.S., kò si pèsè ọ̀nà sí ipò gbígbé ìlú lọ́nà tó bófinmu. Ṣùgbọ́n, ní àwọn ipò kan, àwọn adájọ́ tó ń darí ìlànà ìṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn lè fojú àánú wo níní okòwò àti sísan owó-ìlú.

## Bí a ṣe lè sọ bóyá o jẹ́ agbaṣẹ́ṣe olómìnira

Ó ṣòro láti mọ̀ bóyá o jẹ́ agbaṣẹ́ṣe olómìnira tàbí òṣìṣẹ́, ìwọ sì gbọ́dọ̀ wá ìmọ̀ràn òfin nípa ipò tìrẹ gan-an-gan ní pàtó nígbà gbogbo.

Àwọn agbaṣẹ́ṣe olómìnira ń ṣe okòwò ara tiwọn, wọn a sì máa pèsè ọjà tàbí iṣẹ́ fún àwọn oníbàárà wọn. Bí ìwọ̀n ìṣàkóso ìpèsè ọjà àti iṣẹ́ àti abala ọrọ̀-ajé okòwò rẹ fúnraarẹ̀, yàtọ̀ sì ìṣàkóso tí àwọn oníbàára rẹ ń ṣe, ṣe ga sí, bẹ́ẹ̀ náà ni ó ti ṣeé ṣe tó pé a ó wò ọ́ gẹ́gẹ́ bí agbaṣẹ́ṣe olómìnira yàtọ̀ sí gẹ́gẹ́ bí òṣìṣẹ́ (àwọn) oníbàárà rẹ. Ní ojú-ìwé tó kàn báyìí, ìwọ yóò rí àwọn àpẹẹrẹ àtòjọ kan tó ṣàfiwéra ipò òṣìṣẹ́ sí ti agbaṣẹ́ṣe olómìnira.


Bí o bá dá ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin sílẹ̀ fún okòwò rẹ, ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin náà fúnraarẹ̀ lè pèsè ọjà àti iṣẹ́ fún àwọn oníbàárà. Lápapọ̀, ó ṣeé ṣe kí a má kà ọ́ kún òṣìṣẹ́ **bí o bá ní, tí o sì ń ṣàkóso okòwò tìrẹ**. Fún ìdí èyí, a gbaniníyànjú pé àwọn olùdókòwò tí kò bá ní àṣẹ láti ṣiṣẹ́ láti:

- jẹ́ oníhun gbogbo tàbí púpọ̀ lára okòwò wọn, àti láti
- jẹ́ olùṣàkóso ìmúṣiṣẹ́ okòwò wọn.

# Òṣìṣẹ́ tàbí Agbaṣẹ́ṣẹ Olómìnira?

Èmi ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí aṣètọ́jú-ilé, mo sì máa ń pèsè iṣẹ́ mi fún àwọn oríṣiríṣi oníbàárà. Mo ní ojú-òpó wẹ́ẹ̀bù kan tó ṣàlàyé iye owó iṣẹ́ tí mò ń pèsè. À ń sanwó fún mi fún iṣẹ́ mi, kìí sì ṣe owó-sísan oníwákàtí-wákàtí. Àwọn oníbàárà lè bèèrè fún iṣẹ́ mi nípa yíyan àkókò ìpàdé lórí ayélujára tàbí lórí fóònù. Àwọn oníbàárà ni wọ́n máa ń pèsè àwọn ohun èlò àti irinisẹ́ fún fífọ àwọn nǹkan.

Èmi ń ṣiṣẹ́ bíi aṣètọ́jú-ilé fún ìdílé kan láti Ọjọ́-Ajé sí Ọjọ́-Ẹtì láti aago 8 òwúrọ̀ sí 4 ìrọ̀lẹ́. Mo ṣe ìdúnàádúrà iye owó tí à ń san fún mi sí $15 ní wákàtí kan, mo sì máa ń gbé èyí lọ sókè lọ́dọọdún láti lè kojú iye owó àti-jẹ-àti-mu tó ń lọ sókè nígbà gbogbo. Ìdílé tí mò ń bá ṣiṣẹ́ ni ó ń pèsè gbogbo àwọn ohun èlò fún fífọ nǹkan. Wọ́n máa ń kọ̀wé sílẹ̀ fún mi pẹ̀lú ìtọ́sọ́nà nípa àwọn ohun tó yẹ kí n ṣe ni ọjọ́ yòówù kan pàtó. Ní àwọn ọjọ́ òpin ọ̀sẹ̀, èmi máa ń ṣiṣẹ́ fún àwọn ìdílé mìíràn nígbà mìíràn láti lè pa owó díẹ̀ síi wọlé.




| | Aṣètọ́jú-ilé A | Aṣètọ́jú-ilé B |
|---|---|---|
| Ṣètọ́jú ibi okòwò | | ✓ |
| Níná iye owó tó jọjú sínú iibití o ti ń ṣe owó rẹ, àwọn ohun èlò, àwọn ẹ̀rọ iṣẹ́, àwọn ohun ìpèsè àti àwọn irinṣẹ́ | | |
| Faramọ́ ewu ọrọ̀-ajé fún èrè tàbí àdánù | | ✓ |
| Ṣètò tàbí kí o ronú nípa iye tí ìwọ yóò san fún ara rẹ | ✓ | ✓ |
| O lè yàn láti gba olùrànlọ́wọ́ fún ara rẹ | | ✓ |
| O lè kọ̀jálẹ̀ láti gba iṣẹ́ kan tí a fi lọ̀ọ́ | | ✓ |
| O lè pèsè iṣẹ́ rẹ fún àwọn oníbàárà mìíràn | ✓ | ✓ |
| O lè ṣàkóso bí ìwọ yóò ṣe ṣe iṣẹ́ kan, ìgbà tí ìwọ yóò ṣe é, àti ibití ìwọ yóò ti ṣe é | | ✓ |
| | Mo jẹ́ ÒṢÌṢẸ́ | Mo jẹ́ AGBAṢẸ́ṢẸ OLÓMÌNIRA |

# Òṣìṣẹ́ tàbí Agbaṣẹ́ṣe Olómìnira?

> Mo jẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ akọ̀wé aṣẹ̀ṣirò--owó fún ilé-iṣẹ́ kan nígbàtí wọ́n bá nílò iṣẹ́ mi. Nígbàtí ilé-iṣẹ́ náà bá nílò mi, àwọn ni yóò sọ àwọn ọjọ́ ti èmi yóò ṣiṣẹ́, àti iye àsìkò tí èmi yóò fi ṣiṣẹ́. À ń sanwó fún mi nígbàtí iṣẹ́ náà bá parí, kìí sì ṣe owó-sísan oníwákàtí-wákàtí. Nígbàtí ó bá yẹ kí wọ́n sanwó fún mi, èmi yóò fi àkọsílẹ̀ iye owó tí wọ́n jẹ mí ráńṣẹ́ sí wọn. Èmi ń ṣe irú iṣẹ́ ìṣirò-owó kan náà yìí fún ọ̀pọ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ mìíràn. Èmi ń ṣiṣẹ́ láti ọ́fíìsì inú ilé mi, mo sì máa ń lo ẹ̀rọ kọ̀mputa ti ara mi.

> Mo máa ń ṣiṣẹ́ fún 30 wákàtì lọ́sẹ̀, ní apákan lára ọjọ́ kan fún ilé-iṣẹ́ kan gẹ́gẹ́ bí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ akọ̀wé aṣẹ̀ṣirò--owó, mo sì ń gba owó iṣẹ́ ọlọ́sọ̀ọ̀sẹ̀. Mo máa ń sábà ṣiṣẹ́ láti ilé nípa lílo ẹ̀rọ kọ̀mputa ti ara mi. Bí mo bá fẹ́, mo lè forúkọsílẹ̀ fún àwọn àǹfàní ìlera pẹ̀lú ilé-iṣẹ́ tí mò ń bá ṣiṣẹ́. Nígbà mìíràn, èmi a gba iṣẹ́ lọ́wọ́ àwọn ilé-iṣẹ́ kékèké mìíràn nígbàtí èmi kò bá ní iṣẹ́ tí mò ń ṣe lọ́wọ́ fún ilé-iaẹ́ yìí.



| | Akọ̀wé aṣẹ̀ṣirò--owó A | Akọ̀wé aṣẹ̀ṣirò--owó B |
|---|---|---|
| Ṣètọ́jú ibi okòwò | ✓ | ✓ |
| Níná iye owó tó jọjú sínú iibití o ti ń ṣe owó rẹ, àwọn ohun èlò, àwọn ẹ̀rọ iṣẹ́, àwọn ohun ìpèsè àti àwọn irinṣẹ́ | ✓ | ✓ |
| Faramọ́ ewu ọrọ̀-ajé fún èrè tàbí àdánù | | ✓ |
| Ṣètò tàbí kí o ronú nípa iye tí ìwọ yóò san fún ara rẹ | | ✓ |
| O lè yàn láti gba olùrànlọ́wọ́ fún ara rẹ | | ✓ |
| O lè kọ̀jálẹ̀ láti gba iṣẹ́ kan tí a fi lọ̀ọ́ | | ✓ |
| O lè pèsè iṣẹ́ rẹ fún àwọn oníbàárà mìíràn | ✓ | ✓ |
| O lè ṣàkóso bí ìwọ yóò ṣe ṣe iṣẹ́ kan, ìgbà tí ìwọ yóò ṣe é, àti ibití ìwọ yóò ti ṣe é | | |
| | Mo jẹ́ ÒṢÌṢẸ́ | Mo jẹ́ AGBAṢẸ́ṢE OLÓMÌNIRA |

# Àwọn Ìmọ̀ràn fún Yíyan Ìlànà Okòwò

Nísìnyí tí o ti pinnu láti bẹ̀rẹ̀ okòwò, o gbọ́dọ̀ ronú nípa irú okòwò tí ó tọ́ fún ọ láti ṣe! Abala yìí ń pèsè àlàyé nípa àwọn oríṣiríṣi àṣàyàn tí o ní fún ṣíṣe àgbékalẹ̀ okòwò rẹ.

Àwọn ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò mìíràn ní àwọn òfin àti ìfàkalẹ̀ àwọn ìwé to lọ́júpọ̀, pẹ̀lú iye owó bíbẹ̀rẹ̀ okòwò tó ga púpọ̀. Àwọn okòwò mìíràn lè rọrún díẹ̀ síi láti dásílẹ̀, pẹ̀lú ìfàkalẹ̀ àwọn ìwé tí kò pọ̀ púpọ̀ tàbí ti kó sí rárá tàbí iye owó tí kò ga púpọ̀, ṣùgbọ́n olùdókòwò náà a máa ni ewu àdánù owó tó ga síi. Láti lè yan ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò tó bá àìní rẹ mu jùlọ, ó ṣe pàtàkì láti ní òye àwọn ohun ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ kan nípa àwọn oríṣi okòwò tó wà ní Ìpínlẹ̀ New York.

## Dídáàbòbo Àwọn Ọrọ̀-ajé Araẹni Rẹ

Okòwò lè jẹ́ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin yàtọ̀ sí ẹni tó ni okòwò náà. Ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin, bí ènìyàn kan pàápàá, ní agbára lábẹ́ òfin láti báni ṣe àjọhùn tàbí àgbàṣe, ó lè yá owó tàbí jẹ gbèsè, a lè gbée lọ sílé-ẹjọ́ àti kí a pèé lẹ́jọ́, a sì lè mú kí ó dáhùn fún ohun yòówù tí ó bá ṣe.

Nígbàtí okòwò rẹ bá jẹ́ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin, **ìwọ lè ní ojúṣe araẹni níwọ̀nba**. Ojúṣe rẹ fún àwọn gbèsè okòwò náà mọ níwọ̀nba sí iye owó ara rẹ tí o ná sórí okòwò náà. Bi okòwò rẹ bá jẹ́ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin, tí a sì gbé e lọ sí ilé-ẹjọ́, àwọn ohun-ìní tó jẹ́ ti ara rẹ gẹ́gẹ́ bí ilé tàbí ọkọ̀-ayọ́kẹ́lẹ́ rẹ, wa lábẹ́ ààbò lápapọ̀ lọ́wọ́ gbígbà lọ́wọ́ ẹni láti fi dí àwọn ẹ̀tọ́ owó tó yẹ kí okòwò náà san. Àǹfàní mìíràn tó tún wà nínú mímú okòwo ṣiṣẹ́ nípasẹ̀ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin ni pé ohun náà fúnraarẹ̀ lè ṣe okòwò bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹni tó nií kò ní àṣẹ láti ṣiṣẹ́ tàbí ó ń mú okòwò náà ṣiṣẹ́ láti ibi tó wà lóde U.S.

Nínú ìtọ́sọ̀nà yìí, a ṣe àlàyé ní ṣókí nípa iye owó àti àwọn àǹfàní tó wà nínú àwọn oríṣi ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin tí a lè gbékalẹ̀ ní Ìpínlẹ̀ New York láti lè mú ojúṣe araẹni mọ níwọ̀nba. Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba, Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba àti Ilé-iṣẹ́ Ńlá.

Láti jẹ àǹfàní tó wà nínú **ojúṣe níwọ̀nba** ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin fún okòwò rẹ:


- ríi dájú pé o ya àwọn ohun-ìní tó jẹ́ ti ara rẹ sọ́tọ̀ kúrò lára àwọn ohun-ìní okòwò rẹ
- ṣí àkáùntì ilé-ìfowópamọ́ tó yàtọ̀ fún ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin náà
- lo orúkọ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin nínú àwọn ìgbaṣẹ́ṣe àti ìpolówó ọjà (dípò orúkọ ara rẹ)
- gba nọ́mbà ìdánimọ̀ owó-ìlú (EIN) tó yàtọ̀, kí o sì san owó-ìlú lọ́tọ̀ fún ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin náà nígbà àti níbi tó bà ti nílò bẹ́ẹ̀.

## Kí ni ITIN?

Nigbàtí o bá pa owó wọlé, o ní ojúṣe àti san àwọn owó-ìlú. Nọ́mbà Ìdánimọ̀ Ẹnìkọ̀ọ̀kan Asanwó-ìlú (ITIN) ni àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìpawówọlé Abẹ́lé (IRS) máa ń fún àwọn ènìyàn tí kò kún ojú òṣùwọ̀n láti gba nọ́mbà ààbò àwùjọ ṣùgbọ́n tí wọ́n gbọ́dọ̀ san owó-ìlú. Bí o bá ní nọ́mbà ààbò àwùjọ (SSN), o kò kún ojú òṣùwọ̀n fún ITIN. Kódà bi ọjọ́-orí àṣẹ tí a fún ọ láti ṣiṣẹ́ bá dópin, SSN rẹ ṣì máa ń kún ojú òṣùwọ̀n fún èrèdí Sísan owó-ìlú. O tún lè lo ITIN láti gba ọ̀pọ̀ àwọn iṣẹ́ tó jẹ mọ́ ọrọ̀-ajé títí kan ríráàyèsí ẹ̀yáwó tàbí ṣíṣí àkáùntì ilé-ìfowópamọ́, láì ka ipò ìṣíwá-láti-ìlú-ìbòmíràn rẹ sí. Fún àlàyé síwájú síi, ṣàyẹ̀wò Owó Rẹ, Ọjọ́-ọ̀la Rẹ! Ìtọ́sọ́nà Ìpìlẹ̀ sí Ẹ̀kọ́ àti Ìfagbárafúnni nípa Ọrọ̀-ajé, ohun àmúlò láti ran àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ìbòmíràn lọ́wọ́ láti ní òye àwọn àṣàyàn ọrọ̀-ajé araẹni.

## Kí ni EIN?

Fún èrèdí owó-ìlú ìjọba àpapọ̀ àti Ìpínlẹ̀ New York, okòwò yòówù tó ní àwọn òṣìṣẹ́ gbọ́dọ̀ gba Nọ́mbà Ìdánimọ̀ Agbanisíṣẹ́ (EIN). Àwọn ilé-iṣẹ́ ńláńlá àti ọ̀pọ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ olójúṣe níwọ̀nba (LLC) gbọ́dọ̀ gba EIN. Nígbà púpọ̀, àwọn ilé-ìfowópamọ́ a máa nílò EIN kí okòwò kan tó lè ṣí àkáùntì ilé-ìfowópamọ́. Kí ó báa lè gba EIN, okòwò lè fi Fọ́ọ̀mù SS-4 ("Ìkọ̀wé-bèèrè fún Nọ́mbà Ìdánimọ̀ Agbanisíṣẹ́") kalẹ̀ sọ́dọ̀ IRS tàbí kí ó bèèrè fún èyí nípasẹ̀ fóònù tàbí lórí ayélujára.




## Ní Òye Àwọn Ojúṣe Owó-ìlú Sísan Okòwò Rẹ

Láì ka ipò ìṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn rẹ sí, ẹnikẹ́ni tó ń pawówọlé ní U.S. gbọ́dọ̀ san owó-ìlú fún ìjọba àpapọ̀, ti ìpínlẹ̀ àti ti ìbílẹ̀. Àwọn ojúṣe nípa owó-ìlú dá lórí ọ̀pọ̀ àwọn nǹkan kan lára èyí tó lè jẹ́, bóyá ìwọ ń sanwó ìlú náà gẹ́gẹ́ bí ẹni tó ti ṣè tàbí tí kò tíì ṣe ìgbéyàwó, iye owó tó ń wọlé fún ọ lọ́dún, àti agbègbè ibití ìwọ ń gbé ní Ìpínlẹ̀ New York.

Lápapọ̀, bí àgbékalẹ̀ okòwò rẹ ṣe rọrùn láti mú ṣiṣẹ́ to ni ohun gbogbo tí o ní láti ṣe nípa owó-ìlú sísan rẹ náà yóò ṣe rọrùn tó. Àwọn ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò kan wà tó fààyè gbà ọ́ láti ṣe ìjábọ̀ iye owó tó wọlé sínú okòwò rẹ sórí iye owó-ìlú tó yẹ kí o san lórí iye owó tó wọlé fún ọ gẹ́gẹ́ bí ẹnìkan, èyí tó lè mú ṣíṣètò iye owo-ìlú rọrùn fún àwọn olùdókòwò.


**Jọ̀wọ́ ṣàkíyèsi pé a kò pèsè ìtọ́sọ́nà yìí láti pèsè ìmọ̀ràn nípa owó-ìlú. Àwọn olùdókòwò tó jẹ́ aṣíwá-láti-ìlú-ìbòmíràn ni a gbànímọ̀ràn láti wá ìmọ̀ràn nípa owó-ìlú lọ́wọ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ olùmọ̀ràn owó-ìlú.** Abala àwọn ohun àmúlò náà tún tọ́kasí àwọn àjọ tó kún ojú òṣùwọ̀n láti rannilọ́wọ́ nípa àwọn ìbéèrè tó jẹ mọ̀ ìṣòwò rẹ.

# Ìtàn Kan Nípa Okòwò Méjì

## Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba*

Àwọn ọ̀rẹ́ mẹ́ta kan bẹ̀rẹ̀ okòwò kan papọ̀ tó níí ṣe pẹ̀lú lílа àlà-ilẹ̀ fún gbígbin àwọn ohun tí yóò múu dára síi. Wọn ṣe ìforúkọsílẹ̀ okòwò wọn bíi Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba (LLC). LLC wọn náà jẹ́ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin.


Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rẹ́ náà ná $400 gẹ́gẹ́ bí owó ìbẹ̀rẹ̀ okòwò, **okòwò náà sì yá owó** lọ́wọ́ ilé-ìfowópamọ́.




Okòwò náà kò yọrí sí rere, ó sì dópin lẹ́yìn oṣù mélòó kan pẹ̀lú gbèsè $8,000.




Àdánù náà mọ níwọ̀nba si $400 to jẹ́ iye owó tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rẹ́ tó ni ilé-iṣẹ́ olójúṣe níwọ̀nba náà dá, pẹ̀lú ohun-ìní mìíràn yòówù tí okòwò náà ní.





Àwọn tó ni okòwò náà kò ní ojúṣe gẹ́gẹ́ bí ẹnìkọ̀ọ̀kan fún gbèsè LLC náà, àwọn ohuǹ-ìní wọn sì wà lábẹ́ ààbò.



## Olùdókòwò Àdánìkanni

Olùdókòwò àdánìkanni kan bẹ̀rẹ̀ òwò tirẹ̀ tó jẹ mọ́ lílа àlà ilẹ̀ fún ṣíṣe ọ̀ṣọ́. Òun àti okòwò rẹ̀ jẹ́ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin kan náà lábẹ́ òfin.

Ó ná $400 lára owó-àfipamọ́ rẹ̀ sórí okòwò náà, ó sì yá owó nípasẹ̀ káàdì kírẹ́dìtì **lórúkọ ara rẹ̀** láti fi ra àwọn ẹ̀rọ fún lílò nínú okòwò rẹ̀ tuntun náà.





Okòwò náà kò lọ déédé, ó sì dópin pẹ̀lú gbèsè $8,000 lórí káàdì kírẹ́dìtì rẹ̀.




Olùdókòwò àdánìkanni náà ti pàdánù $400 tó ná sínú okòwò rẹ̀, òun sì ni ó ni ojúṣe láti san $8,000 to jẹ́ gbèsè orí káàdì rẹ̀ padà pẹ̀lú àsanlé.




Bí òun kò bá san gbèsè náà padà, àwọn ilé-iṣẹ́ tó fún-un ní káàdì kírẹ́dìtì náà yóò bẹ̀rẹ̀ sí lé e kiri láti gba àwọn ohun-ìní rẹ̀ láti fi san gbèsè náà padà, èyí tó kan ọkọ̀-ayọ́kẹ́lẹ́ rẹ̀, ilé àti owó-àfipamọ́ ti ara rẹ̀!



*A tọ́ka sí LLC nínú àpẹẹrẹ yìí, ṣùgbọ́n àwọn orísìi ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin mìíràn tí a ó mẹ́nubà níbòmíràn nínú ìtọ́sọ́nà yìí dín ojúṣe araẹni kù bákan náà.

# ÀWỌN ÌLÀNÀ ÀGBÉKALẸ̀ OKÒWÒ MẸ́FÀ TÓ WỌ́PỌ̀

Àwọn àpẹẹrẹ jíjẹ́ oníhun okòwò oríṣi mẹ́fà tó wọ́pọ̀ ni ó wà ní Ìpínlẹ̀ New York tó jẹ́ pàtàkì fún àwọn olùdókòwò aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn. Àwọn wọ̀nyí ni:

- **Okòwò Àdánìkanni**
- **Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Gbogbogbò**
- **Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba**
- **Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba**
- **Ilé-iṣẹ́ Ńlá**
- **Alájẹṣẹ́kù Ọ̀ṣìṣẹ́**

Ìtọ́sọ́nà yìí pèsè àtúnyẹ̀wò lápapọ̀ nípa àwọn ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò márùn-ún àkọ́kọ́. A lè dá alájẹṣẹ́kù sílẹ̀ nípasẹ̀ àjùmọ̀ṣepọ̀, LLC, tàbí ilé-iṣẹ́ ńlá. Nítorí ṣíṣe pàtàkì ìlànà àgbékalẹ̀ rẹ̀, ìtọ́sọ́nà yìí kò pèsè àlàyé lẹ́kunrẹrẹ nípa àwọn ohun tí okòwò nílò àti àwọn ojúṣe okòwò láti jẹ́ alájẹṣẹ́kù. Fún àlàyé síwájú síi nípa àwọn alájẹṣẹ́kù, wo abala àwọn ohun àmúlò.

# Okòwò Àdánìkanni

Okòwò Àdánìkanni jẹ́ ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò tó rọrùn jùlọ tí o lè lò láti fi mú okòwò ṣiṣẹ́, ó sì tún jẹ́ èyí tó rọrùn jù láti dásílẹ̀. O tilẹ̀ lè ti jẹ́ olùdókòwò àdánìkanni bí o bá ti ń pèsè iṣẹ́ tàbí tí ò ń ta àwọn ọjà, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé o kò kó àwọn ìwé kankan lọ sọ́dọ̀ ìjọba. Iye owó ìbẹ̀rẹ̀ okòwò kéré nítorí o kò nílò láti sanwó tàbí fa fọ́ọ̀mù kalẹ̀ bíi ti àwọn ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò yòókù. Ìwọ yóò máa jábọ̀ iye owó tó ń wọlé fún okòwò rẹ papọ̀ pẹ̀lú owó-ìlú ti ara rẹ, nípa bẹ́ẹ̀ ìṣètò owó-ìlú tó yẹ láti san yóò rọrùn.

## Àlàyé ní Ṣókí Nípa Okòwò Àdánìkanni

| | | |
|---|---|---|
| Iye àwọn oníhun | **Oníhun 1** | Ẹni náà nìkan ni ó ni okòwò náà. |
| Ìbẹ̀rẹ̀ okòwò | **Rọrùn jùlọ láti bẹ̀rẹ̀** | Ti bẹ̀rẹ̀ lọ́gán tí o bá ti ń ṣe akitiyan okòwò. |
| Iye owó fún sísan/ Àwọn Fọ́ọ̀mù | **Òfo sí kékeré** | *(Kò pọn dandan)* Owó ìfàkalẹ̀ ìwé to jẹ́ déédé, èyí tó máa ń yàtọ̀ láti agbègbè kan sí òmíràn, fún Ìwé-ẹ̀rí Orúkọ tí a Yàn Láti Máa Jẹ́ bí orúkọ okòwò náà bá yàtọ̀ sí ti oníhun. |
| Ìṣètò Owó-ìlú | **Kò díjú púpọ̀** | Ìwọ yóò máa jábọ̀ iye owó tó ń wọlé fún okòwò sórí iye owó tó ń wọlé ti ara rẹ fún èrèdí owó-ìlú. |
| Ojúṣe | **Ewu owó ọrọ̀-ajé araẹni tó ga** | Olùdókòwò tó ni okòwò náà ni ó ni ojúṣe fún gbogbo gbèsè àti àwọn ojúṣe okòwò náà mìíràn, àwọn ohun-ìní araẹni rẹ̀ sì wà lábẹ́ ewu. |
| Àwọn Ohun tí o Nílò tó ń lọ Lọ́wọ́ | **Kò sí àtúnsọdọ̀tun/ ìfàkalẹ̀ ìwé** | O kò nílò láti fa àfikún ìwé kankan kalẹ̀ fún ilé-iṣẹ́ ìjọba yòówù láti lè máa jẹ́ ẹni tó dánìkan ni okòwò. |
| Ó dára fún | Àwọn ìpèsè iṣẹ́ tó jẹ mọ́ titún ohun èlò tí ń lo iná-mọ̀nàmọ́ná ṣe, líla àlà ilẹ̀ fún ọ̀ṣọ́, aṣètọ́jú-ilé, olùkọ́ni, olùkọ̀wé àti ayàwòrán | |

# Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Gbogbogbò

Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Gbogbogbò a máa ṣiṣẹ́ dáradára fún àwọn oníhun okòwò tó jẹ́ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí wọ́n ń fẹ́ láti ṣàjọpín ojúṣe tàbí ewu owó ọrọ̀-ajé, tí wọ́n sì jọ ń ṣe ìpinnu nípa okòwò náà papọ̀. Èyí a máa ṣiṣẹ́ fún àwọn olùdókòwò tí wọ́n ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú ara wọn nítorí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn alájọṣepọ̀ náà ni ó ni ojúṣe fún àwọn ìpinnu yòówù tí àwọn alájọṣepọ̀ yòókù bá ṣe.

Bíi okòwò àdánìkanni, kò sí ìfàkalẹ̀ ìwé kankan lọ títí láti ṣàgbékalẹ̀ àbáṣiṣẹ́pọ̀ gbogbogbò. O tilẹ̀ lè ti wà nínú àbáṣiṣẹ́pọ̀ gbogbogbò bí o bá ti lọ́wọ́ nínú ṣíṣe okòwò pẹ̀lú ẹlòmíràn, tí ẹ sì rí ara yín bíi aláàbáṣiṣẹ́pọ̀ nínú okòwò. A gbaniníyànjú gidi gan pé kí àwọn alájọṣepọ̀ ṣe àjọhùn àbáṣiṣẹ́pọ̀, àkọsílẹ̀ pàtàkì tó ń ṣàlàyé ohun tí ẹ̀tọ́ àti ojúṣe alájọṣepọ̀ kọ̀ọ̀kan jẹ́, àti bí àwọn alájọṣepọ̀ náà yóò ṣe máa wá ọ̀nà-àbáyọ sí ìṣòro. Àfi bí àjọhùn àbáṣiṣẹ́pọ̀ kan bá wà tó sọ ohun mìíràn, gbogbo àwọn èrè àti àdánù yóò jẹ́ pípín dọ́gba-dọ́gba laarin àwọn alájọṣepọ̀ náà. **Wá ìrànlọ́wọ́ amòfin nípa ṣíṣàgbékalẹ̀ àjọhùn àbáṣiṣẹ́pọ̀.**

Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà fún okòwò àdánìkanni, àwọn ohun-ìní araẹni kò sí lábẹ́ ààbò nínú àbáṣiṣẹ́pọ̀ gbogbogbò, bẹ́ẹ̀ sì ni àwọn ohun-ìní araẹni ti alájọṣepọ̀ kan lè wà lábẹ́ ewu nítorí ìṣèpinnu tí kò tọ́ latọwọ́ alájọṣepọ̀ kejì.

## Àwọn Àjọhùn Àbáṣiṣẹ́pọ̀

Àjọhùn àbáṣiṣẹ́pọ̀ jẹ́ àkọsílẹ̀ pàtàkì kan tó ṣàlàyé àwọn ohun tí ẹ̀tọ́ àti ojúṣe alájọṣepọ̀ kọ̀ọ̀kan jẹ́ nípa okòwò náà. Àwọn àjọhùn àbáṣiṣẹ́pọ̀ ni a gbaniníyànjú gidi láti ṣe fún àbáṣiṣẹ́pọ̀ gbogbogbò, a sì nílò rẹ̀ pàápàá fún àwọn àbáṣiṣẹ́pọ̀ oníwọ̀nba. Àjọhùn àbáṣiṣẹ́pọ̀ a máa pèsè ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè wọ̀nyí:

- Èló ni ọ̀kọ̀ọ̀kan alájọṣepọ̀ ń fi sínú okòwò?
- Kí ni àwọn ojúṣe ọ̀kọ̀ọ̀kan alájọṣepọ̀?
- Báwo ni àwọn alájọṣepọ̀ náà yóò ṣe máa ṣe ípinnu?
- Báwo ni àwọn alájọṣepọ̀ náà yóò ṣe máa ṣàjọpín èrè àti àdánù?
- Báwo ni àwọn alájọṣepọ̀ náà yóò ṣe máa wá ojúùtú sí èdèàìyedè?
- Kí ni yóò ṣẹlẹ̀ bí alájọṣepọ̀ kan bá pinnu láti yọ ọwọ́ kúrò nínú okòwò náà tàbí láti ta iye ohun tó jẹ́ tirẹ̀ lára okòwò náà?

## Àlàyé ní Ṣókí Nípa Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Gbogbogbò

| | | |
|---|---|---|
| Iye àwọn oníhun | **Oníhun 2 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ** | Àwọn alájọṣepọ̀ ni ó jọ ni okòwò |
| Ìbẹ̀rẹ̀ okòwò | **Rọrùn jùlọ láti bẹ̀rẹ̀** | Ti bẹ̀rẹ̀ lọ́gán tí o bá ṣe akitiyan okòwò. |
| Iye owó fún sísan/ Àwọn Fọ́ọ̀mù | **Òfo sí kékeré** | *(Kò pọn dandan)* Owó ìfàkalẹ̀ ìwé to jẹ́ déédé, èyí tó máa ń yàtọ̀ láti agbègbè kan sí òmíràn, fún Ìwé-ẹ̀rí Orúkọ tí a Yàn Láti Máa Jẹ́ bí orúkọ okòwò náà bá yàtọ̀ sí ti oníhun. A gbaniníyànjú gidi gan láti ṣe Àjọhùn Àbáṣiṣẹ́pọ̀. |
| Ìṣètò Owó-ìlú | **Kò díjú púpọ̀** | Àwọn alájọṣepọ̀ yóò máa jábọ̀ iye owó tó ń wọlé fún okòwò sórí iye owó tó ń wọlé ti ara wọn fún èrèdí owó-ìlú. Ìjábọ̀ tó ṣàlàyé iye owó-ìlú fún àjọṣepọ̀ náà ni wọ́n gbọ́dọ̀ ṣe ìfàkalẹ̀ àkọsílẹ̀ rẹ̀ pẹ̀lú. |
| Ojúṣe | **Ewu owó ọrọ̀-ajé araẹni tó ga** | Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn alájọṣepọ̀ náà ní ó lè nílò láti dáhùn fún àwọn ìgbésẹ̀ alájọṣepọ̀ yòówù lára wọn. Àwọn ohun-ìní tó jẹ́ ti araẹni wà lábẹ́ ewu. |
| Àwọn Ohun tí o Nílò tó ń lọ Lọ́wọ́ | **Kò sí àtúnsọdọ̀tun/ ìfàkalẹ̀ ìwé** | O kò nílò láti fa ohunkóhun kalẹ̀ fún ìjọba láti mú kí okòwò rẹ lè tẹ̀síwájú ní ipò rẹ̀ lábẹ́ òfin. |
| Ó dára fún | Àwọn Okòwò Ìdílé • Àwọn alájọṣepọ̀ tó ní ìbáratàn ọlọ́jọ́pípẹ́, tí wọ́n sì ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú ara wọn. | |

# Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba

Nínú àbáṣiṣẹ́pọ̀ oníwọ̀nba, oríṣi oníhun méjì ni ó wà, alájọṣepọ̀ gbogbogbò kan àti alájọṣepọ̀ oníwọ̀nba kan. **Alájọṣepọ̀ gbogbogbò** a máa ṣiṣẹ́ ní ọ̀nà kan náà bíi oníhun tó ní okòwò àdánìkanni tàbí àbáṣiṣẹ́pọ̀ gbogbogbò nítorí pé wọ́n máa ń ṣàkóso okòwò àbáṣiṣẹ́pọ̀ oníwọ̀nba náà, wọ́n máa ń fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn ẹlòmíràn láti ṣe okòwò, wọ́n máa ń ṣe ìpinnu, wọ́n sì máa ń gbé ìgbésẹ̀ lórúkọ àjọṣepọ̀ náà.

**Alájọṣepọ̀ oníwọ̀nba** jẹ́ abánidókòwò tí kìí ṣe ohunkóhun. Wọ́n máa ń ná owó sórí okòwò, wọ́n sì máa ń gba ìpín tó jẹ́ tiwọn lára èrè rẹ̀, ṣùgbọ́n wọn kò lè ṣàkóso akitiyan ojoojúmọ́ nípa okòwò náà tàbí kí wọ́n gbé ìgbésẹ̀ lórúkọ àjọṣepọ̀ náà. Yàtọ̀ sí àwọn alájọṣepọ̀ gbogbogbò, àwọn ohun-ìní araẹni ti alájọṣepọ̀ oníwọ̀nba wà lábẹ́ ààbò. Ojúṣe alájọṣepọ̀ oníwọ̀nba mọ níwọ̀nba sí iye owó tó ná sórí okòwò náà.

Àjọṣepọ̀ oníwọ̀nba nílò iṣẹ́ tó pọ̀ púpọ̀ láti bẹ̀rẹ̀ ju okòwò àdánìkanni tàbí àbáṣiṣẹ́pọ̀ gbogbogbò lọ nítorí ìwọ yóò nílò láti fa ọ̀pọ̀ ìwé kalẹ̀ pẹ̀lú Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀ New York (DOS), ìwọ yóò sì san iye owó tó níí ṣe pẹ̀lú èyí. Ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò yìí dára fún àwọn oníhun tó ní àwọn tó náwó sínú okòwò wọn ṣùgbọ́n tí wọn kò fẹ́ láti kópa nínú ìṣàkóso okòwò náà tàbí láti ní ojúṣe yòówù nípa ìpinnu tí alájọṣepọ̀ gbogbogbò bá ṣe nípa okòwò náà. Àwọn àjọhùn àjọṣepọ̀ oníwọ̀nba gbọ́dọ̀ wà ní àkọsílẹ̀ nínú Àjọhùn Àbáṣiṣẹ́pọ̀ (wo ojú-ìwé 17).

### Ìkéde Inú Ìwé-ìròyìn

Àwọn Ilé-iṣẹ́ Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba àti Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba nílò láti ṣàtẹ̀jáde ìdásílẹ̀ okòwò wọn nínú ìwé-ìròyìn ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ méjì fún ọ̀sẹ̀ mẹ́fà tó tẹ̀lé ara wọn. Iye owó fún ṣíṣe àtẹ̀jáde nínú ìwé-ìròyìn lè pọ̀ púpọ̀, èyí sì dá lórí agbègbè.

| Alájọṣepọ̀ **Gbogbogbò** | Alájọṣepọ̀ **Oníwọ̀nba** |
|---|---|
| ▶ Máa n náwó sínú okòwò, wọn a sì gba ìpín tiwọn nínú èrè rẹ̀<br>▶ Máa ń ṣàkóso okòwò, wọn a sì máa ṣe ìpinnu nípa okòwò<br>▶ Máa ń gbé ìgbésẹ̀ lórúkọ àjọṣepọ̀ náà<br>▶ Wọ́n ní ojúṣe fúnraara wọn fún gbèsè okòwò náà (Oníhun okòwò kan lè ṣàgbékalẹ̀ ohun ọ̀tọ̀ kan tó dádúró lábẹ́ òfin láti dúró bíi Alájọṣepọ̀ Gbogbogbò láti pèsè ojúṣe níwọ̀nba, ṣùgbọ́n èyí a máa mú ohun gbogbo lọ́júpọ̀ síwájú síi.) | ▶ Máa n náwó sínú okòwò, wọn a sì gba ìpín tiwọn nínú èrè rẹ̀<br>▶ Kìí ṣàkóso okòwò<br>▶ Kò lè gbé ìgbésẹ̀ lórúkọ àjọṣepọ̀ náà<br>▶ Àwọn ohun-ìní tó jẹ́ ti araẹni wà lábẹ́ ààbò. Ewu ọrọ̀-ajé náà mọ níwọ̀nba sí iye owó tó ná sínú okòwò náà ní ìbẹ̀rẹ̀. |

## Àlàyé ní Ṣókí Nípa Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba

| | | |
|---|---|---|
| Iye àwọn oníhun | **Oníhun 2 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ** | Oríṣi à wọn oníhun méjì ni ó wà, ó sì kéré jù, wọ́n yóò nílò ọ̀kan lára ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn: alájọṣepọ̀ gbogbogbò kan àti alájọṣepọ̀ oníwọ̀nba kan. |
| Ìbẹ̀rẹ̀ okòwò | **Ó nílò akitiyan tó pọ̀ púpọ̀ láti bẹ̀rẹ̀** | Nílò àwọn ìwé àkọsílẹ̀ láti ṣàgbékalẹ̀:<br>▶ Ìwé-ẹ̀rí Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba<br>▶ Ìwé-ẹ̀rí Àtẹ̀jáde àti Ìbúra nípa Àtẹ̀jáde (lẹ́yìn àtẹ̀jáde nínú ìwé-ìròyìn) |
| Iye owó fún sísan/ Àwọn Fọ́ọ̀mù | **Ó wọ́n níwọ̀nba** | $200 owó ìfàkalẹ̀ ìwé àkọsílẹ̀, $50 owó ìfàkalẹ̀ Ìwé-ẹ̀rí Àtẹ̀jáde, àti $600-$1,200 tó jẹ́ owó àtẹ̀jáde nínú ìwé-ìròyìn. Nílò àjọṣepọ̀ àbáṣiṣẹ́pọ̀. |
| Ìṣètò Owó-ìlú | **Kò díjú púpọ̀** | Ìwọ yóò máa jábọ̀ iye owó tó ń wọlé fún okòwò sórí iye owó tó ń wọlé ti ara rẹ fún èrèdí owó-ìlú. Ìjábọ̀ tó ṣàlàyé iye owó-ìlú fún àjọṣepọ̀ náà ni wọ́n gbọ́dọ̀ ṣe ìfàkalẹ̀ àkọsílẹ̀ rẹ pẹ̀lú. |
| Ojúṣe | **Ewu tó ga púpọ̀ fún àwọn alájọṣepọ̀ gbogbogbò** | Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn alájọṣepọ̀ gbogbogbò ni ó ni ojúṣe fún igbèsè okòwò náà. Ojúṣe alájọṣepọ̀ oníwọ̀nba mọ níwọ̀nba sí ohun tí wọ́n fi sínú okòwò náà. |
| Àwọn Ohun tí o Nílò tó ń lọ Lọ́wọ́ | **Bẹ́ẹ̀ni** | Àjọhùn àbáṣiṣẹ́pọ̀ tí a kọsílẹ̀ pọn dandan, a`wọn alájọṣepọ̀ gbogbogbò náà sì gbọ́dọ̀ fọwọ́sí à jọhùn náà. |
| Ó dára fún | Àwọn olùdókòwò tó ní alájọṣepọ̀ tó fẹ́ láti ná owó sínú okòwò ṣùgbọ́n tí wọn kò fẹ́ láti ní ohunkóhun ṣe pẹ̀lú ṣíṣe ìpinnu tàbí láti ní ojúṣe araẹni nínú okòwò náà. | |

# Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba

Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba (LLC) ń pèsè ojúṣe tó mọ níwọ̀nba tàbí ewu ọrọ̀-ajé araẹni tó kéré síi, èyí tó jẹ́ àǹfàní ńlá tó rékọjá okòwò àdánìkanni àti ìlànà àgbékalẹ̀ àjọṣepọ̀. Lábẹ́ òfin, okòwò jẹ́ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin yàtọ̀ sí (àwọn) tó ni okòwò, gbogbo (àwọn) oníhun náà ní ààbò lórí ohun-ìní tó jẹ́ ti ara wọn. Láti lè máa ní ojúṣe tó mọ níwọ̀nba, àwọn oníhun náà gbọ́dọ̀ ṣí àkáùntì ilé-ìfowópamọ́ tó yàtọ̀ fún LLC náà, wọ́n gbọ́dọ̀ ná iye owó tó tó sínú LLC náà kí ó lè máa rí owó ná fún ìtẹ̀síwájú ara rẹ̀, wọn kò gbọdọ̀ da àwọn ohun-ìní ti ara wọn pọ̀ mọ́ àwọn ohun-ìní ti okòwò náà, wọn kò sì gbọdọ̀ lo owó LLC náà fún ìnáwó ti ara wọn.

Àwọn oníhun, tí a mọ̀ sí ọmọ-ẹgbẹ́ nínú LLC, lè yàn láti ṣàkóso okòwò náà fúnraara wọn tàbí kí wọ́n yan àwọn olùṣàkóso láti máa ṣàkóso okòwò náà. A lè ka àwọn olùṣàkóso kún òṣìṣẹ́, nítorí náà, wọn yóò nílò láti máa gba àṣẹ kí wọ́n tó lè ṣiṣẹ́. **Òfin kò sọ àsọyé ní abala yìí, nítorí náà àwọn ẹnití kò ní àṣẹ láti ṣiṣẹ́ gbọ́dọ̀ wá ìmọ̀ràn amòfin kí a tó yàn wọ́n gẹ́gẹ́ bí olùṣàkóso LLC, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n jẹ́ ara àwọn oníhun LLC náà.**

Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ LLC lè yàn bí wọ́n ṣe fẹ́ kí LLC náà máa san owó-ìlú nígbàtí wọ́n bá ṣàgbékalẹ̀ rẹ̀ tán. Àfi bí wọ́n bá fa ìwé àkọsílẹ̀ kalẹ̀ pẹ̀lú IRS nínú èyítí wọ́n ti yàn pé kí LLC náà máa san owó-ìlú bíi ilé-iṣẹ́ ńlá, àwọn oníhun lè máa ṣe ìjábọ̀ iye owó tó wọlé fún okòwò náà papọ̀ pẹ̀lú iye owó-ìlú ti ara wọn. **Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ LLC gbọ́dọ̀ wá ìmọ̀ràn látọ̀dọ̀ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ owó-ìlú nípa àwọn àṣàyàn tó wà.**



## Àjọhùn Iṣẹ́-ṣíṣe

Àjọhùn iṣẹ́-ṣíṣe jẹ́ ì wé àkọsílẹ̀ pàtàkì tí àwọn LLC máa ń lò, èyí tó máa ń sọ nípa àwọn ẹ̀tọ́, agbára, àti ojúṣe àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ rẹ̀, ti àwọn olùṣàkóso, òṣìṣẹ́ àti àwọn aṣojú. A lè ṣe Àjọhùn Iṣẹ́-ṣíṣe náà ṣáájú, ní àkókò, tàbí laarin ọjọ́ 90 lẹ́yìn ti a ti fi Àkọsílẹ̀ Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba náà kalẹ̀ sọ́dọ̀ àwọn aláṣẹ.

# Àlàyé ní Ṣókí Nípa Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba (LLC)

| | | |
|---|---|---|
| Iye àwọn oníhun | **Oníhun 1 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ** | LLC lè ní ọmọ-ẹgbẹ́ oníhun kanṣoṣo tàbí ọmọ-ẹgbẹ́ púpọ̀ tó ni LLC náà |
| Ìbẹ̀rẹ̀ okòwò | **Ó nílò akitiyan tó pọ̀ púpọ̀ láti bẹ̀rẹ̀** | Nílò àwọn ìwé àkọsílẹ̀ láti ṣàgbékalẹ̀:<br>▶ Àkọsílẹ̀ Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba<br>▶ Ìwé-ẹ̀rí Àtẹ̀jáde àti Ìbúra nípa Àtẹ̀jade náà (lẹ́yìn àtẹ̀jade nínú ìwé-ìròyìn) |
| Iye owó fún sísan/ Àwọn Fọ́ọ̀mù | **Ó wọ́n** | $200 owó ìfàkalẹ̀ Àkọsílẹ̀ Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba, $50 owó ìfàkalẹ̀ Ìwé-ẹ̀rí Àtẹ̀jáde, àti $600-$1,200 tó jẹ́ owó àtẹ̀jáde nínú ìwé-ìròyìn. Nílò àjọhùn iṣẹ́-ṣíṣe. |
| Ìṣètò Owó-ìlú | **Ó lọ́júpọ̀ níwọ̀nba** | LLC ní àwọn oríṣiríṣi àṣàyàn tó dá lórí ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò náà àti iye àwọn ọmọ-ẹgbẹ́. |
| Ojúṣe | **Ojúṣe / ewu owó ọrọ̀-ajé tí kò pọ̀** | Okòwò náà jẹ́ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin yàtọ̀ sí (àwọn) oníhun okòwò náà. Àwọn oníhùn ní ojúṣe tó mọ níwọ̀nba, ojúṣe igbèsè wọn kò sì ju iye owó tí wọ́n ná sínú okòwò náà lọ. |
| Àwọn Ohun tí o Nílò tó ń lọ Lọ́wọ́ | **Bẹ́ẹ̀ni – kíkọ́ ohun gbogbo sílẹ̀ ní ìpamọ́ tó wà títí** | ▶ Wọn a máa fọwọ́sí Àjọhùn Iṣẹ́-ṣiṣe laarin ọjọ́ 90 lẹ́yìn tí wọ́n fa Ìwé-ẹ̀rí Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ wọn kalẹ̀.<br>▶ *(Kò pọn dandan)* Wọn a máa pe ìpàdé àwọn ọmọ-ẹgbẹ́/olùṣàkóso wọn<br>▶ Wọn a máa ṣàfipamọ́ àwọn àkọsílẹ̀ kan nípa LLC àti owó-ìlú<br>▶ Wọn a máa fa Àkọsílẹ̀ Àlàyé Ọlọ́dún-Méjì kalẹ̀ lọ́dọọdún méjì-méjì láti jẹ̀rìísí/ṣe ìmúdójúìwọn àdírẹ́ẹ̀sì wọn |
| Ó dára fún | Wọ́n jẹ́ àwọn oníhun tó fẹ́ láti ya àwọn owó-àfipamọ́ àti ọrọ̀-ajé ti ara wọn sọ́tọ̀ kúrò lára okòwò wọn, wọ́n sì lè ṣàkóso àwọn àìní tó lè máa yọjú. | |


# Ilé-iṣẹ́ Ńlá

A máa ń sábà lo ilé-iṣẹ́ ńlá fún àwọn okòwò tó tóbi pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ oníhun nítorí ó ní agbára láti fúnni ní ìpín èrè ilé-iṣẹ́ ńlá. Ìpín èrè ilé-iṣẹ́ ńlá jẹ́ ohun tó jẹ́ ti ẹni nínú ilé-iṣẹ́ ńlá náà. Dídá ilé-iṣẹ́ ńlá sílẹ̀ nílò iṣẹ́ ìwé kíkọsílẹ̀ tó pọ̀ púpọ̀, ó sì ní àwọn owó tó wà fún sísan àti àwọn ohun tó yẹ fún ṣíṣe lábẹ́ òfin nígbà gbogbo.

Ọ̀kọ̀ọ̀kan ilé-iṣẹ́ ńlá gbọ́dọ̀ ní òfin ìṣesí, ìgbìmọ̀ àwọn adarí, àti àwọn òṣìṣẹ́ aṣàkóso. Lẹ́yìn tí a bá ti ṣàgbékalẹ̀ ilé-iṣẹ́ ńlá náà tán, àwọn aṣàjọpín-èrè gbọ́dọ̀ ṣe ìpàdé ìṣètò láti fọwọ́sí àwọn òfin ìṣesí náà, kí wọ́n sì yan àwọn adarí. Ilé-iṣẹ́ ńlá kìí ṣe ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò tó yẹ fún olùdókòwò tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń bẹ̀rẹ̀ okòwò kékeré. LLC a máa fún olùdókòwò kékeré ní gbogbo àwọn àǹfàní tó wà nínú ilé-iṣẹ́ ńlá láìsí àwọn ìlọ́júpọ̀ to wà nínú ilé-iṣẹ́ ńlá, pẹ̀lú agbára láti yí nǹkan padà àti ìmúdúró tó rọrùn síi.

Síwájú síi, ìlànà àgbékalẹ̀ ilé-iṣẹ́ ńlá ní ewu tó pọ̀ nígbà púpọ̀ fún olùdókòwò tó jẹ́ aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn tí kò ní àṣẹ láti ṣiṣẹ́. Bí olùdókòwò náà bá ń ṣàkóso okòwò náà bíi òṣìṣẹ́ aṣàkóso ilé-iṣẹ́ ńlá náà, tàbí ilé-iṣẹ́ ńlá náà ń sanwó iṣẹ́ ìgbà-dé-ìgbà fún un, ó ṣeé ṣe púpọ̀ láti kàá kún òṣìṣẹ́ tí a gbàsíṣẹ́. Láti ríi dájú pé o ṣàgbékalẹ̀ okòwò rẹ, o sì ń ṣàkóso rẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú àwọn òfin tó yẹ, èyí tó kan àwọn òfin owó-ìlú ìjọba ìpínlẹ̀ àti ti ìbílẹ̀, ríi dájú pé o gba ìmọ̀ràn àti ìyànjú amòfin lásìkò tí o bá ń ṣákójọ ètò okòwò rẹ. Ìṣàkóso owó-ìlú àwọn ilé-iṣẹ́ ńláńlá lọ́júpọ̀ púpọ̀, ó sì kọjá ìwọ̀n òye ìtọ́sọ́nà yìí.

## Ìlànà Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Ńlá




Ẹnìkan tó ra ìpín ilé-iṣẹ́ ńlá náà, tó sì ní iye ìwọ̀n kan nínú ọgọ́ọ̀rún lára ilé-iṣẹ́ náà, èyí tó dá lórí iye ìpín tí wọ́n ní. Nígbàtí a bá ṣàgbékalẹ̀ ilé-iṣẹ́ ńlá, nígbà púpọ̀, àwọn oníhun rẹ̀ ni wọ́n máa ń kọ́kọ́ jẹ́ aṣàjọpín-èrè.

Àkójọpọ̀ àwọn ènìyàn kan tí a yàn láti ṣojú fún ohun tó jẹ́ ti àwọn aṣàjọpín-èrè. Àwọn adarí náà lè jẹ́ aṣàjọpín-èrè, ṣùgbọ́n kò pọn dandan. Ìgbìmọ̀ kan gbọ́dọ̀ ní, ó kéré, adarí kan nínú. Àwọn adarí ni ó ni ojúṣe àbojútó lápapọ̀, àti ṣíṣe ìpinnu nípa àwọn ohun tó jẹ́ kókó ní ilé-iṣẹ́ náà.

Wọ́n ní ojúṣe fún ìṣàkóso ojoojúmọ́ okòwò náà, wọ́n sì ní àṣẹ láti gbé ìgbésẹ̀ lórí àwọn ohun tó jẹ mọ́ okòwò náà. **A lè ka àwọn òṣìṣẹ́ àṣàkóso kún òṣìṣẹ́ tí a gbàsíṣẹ́ lábẹ́ òfin, a sì lè ní kí wọ́n mú ẹ̀rí wá nípa ipò wọn láti ṣiṣẹ́ ní U.S.**

## Àlàyé ní Ṣókí Nípa Ilé-iṣẹ́ Ńlá

| | | |
|---|---|---|
| Iye àwọn oníhun | **Oníhun 1 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ** | Àwọn ilé-iṣẹ́ ńláńlá máa ń sábà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn oníhun, tí a mọ̀ sí aṣàjọpín-èrè, ṣùgbọ́n a tún lè ṣàgbékalẹ̀ rẹ̀ pẹ̀lú aṣàjọpín-èrè kanṣoṣo. |
| Ìbẹ̀rẹ̀ okòwò | **Ó nílò akitiyan tó pọ̀ púpọ̀ síi láti bẹ̀rẹ̀** | Lẹ́yìn tí a bá ti fa Ìwé-ẹ̀rí Ìdásílẹ̀ Ilé-iṣẹ́ kalẹ̀ tán, ìpàdé ìṣètò gbọ́dọ̀ wáyé láti fọwọ́sí àwọn òfin ìṣesí àti láti yan ìgbìmọ̀ àwọn adarí. |
| Iye owó fún sísan/ Àwọn Fọ́ọ̀mù | **Ó wọ́n púpọ̀** | $125 owó ìfikalẹ̀ Ìwé-ẹ̀rí Ìdásílẹ̀ Ilé-iṣẹ́ wà láti san láti bẹ̀rẹ̀ ilé-iṣẹ́ ńlá. Ó ṣeé ṣe púpọ̀ fún Ilé-iṣẹ́ ńlá láti mú ni san iye owó tó pọ̀ fún ìmòfin àti ìṣèṣírò owó. |
| Ìṣètò Owó-ìlú | **Ó lọ́júpọ̀ púpọ̀** | A gba àwọn olùdókòwò níyànjú láti kàn sí akọ̀ṣẹ́mọṣẹ́ nípa owó-ìlú láti ní òye àwọn ojúṣe wọn nípa owó-ìlú. |
| Ojúṣe | **Ojúṣe/ ewu owó ọrọ̀-ajé tí kò pọ̀ rárá** | Okòwò náà jẹ́ ohun kan tó dádúró lábẹ́ òfin yàtọ̀ sí (àwọn) oníhun okòwò náà. Ojúṣe oníhun láti san gbèsè mọ níwọ̀nba sí iye owó tí wọ́n ná sínú okòwo náà. |
| Àwọn Ohun tí o Nílò tó ń lọ Lọ́wọ́ | **Bẹ́ẹ̀ni – Àwọn Ohun tí o Nílò tó ń lọ Lọ́wọ́ to ṣòro gidi** | ▶ Ìpàdé aṣàjọpín-èrè pàtàkì àti lọ́dọọdún<br>▶ Ìpàdé (àwọn) Ìgbímọ̀ Adarí pàtàkì a`ti láti ìgbà-dé-ìgbà<br>▶ Ìpamọ́ ìjíròrò ìpàdé àti àkọsílẹ̀ fún àwọn ìwé owó-ìlú ilé-iṣẹ́ ńlá<br>▶ Wọn a máa fa Àkọsílẹ̀ Àlàyé Ọlọ́dún-Méjì kalẹ̀ lọ́dọọdún méjì-méjì láti jẹ̀rìísí/ṣe ìmúdójúìwọ̀n àdírẹ́ẹ̀sì wọn |
| Ó dára fún | Àwọn okòwò ńláńlá tó ní àwọn oníhun tó pọ̀ púpọ̀ tó nílò láti ná owó tó pọ̀ sínú okòwò, tí wọ́n sì fẹ́ láti máa ṣàgbéjáde àti láti máa ṣòwò ìpín ilé-iṣẹ́ ńlá. | |

# Àfiwéra Ní Kíá -- Irú ìlànà okòwò wo ni ó tọ́ fún ọ?


| | Okòwò Àdáǹìkanni | Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Gbogbogbò | Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba | Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba | Ilé-iṣẹ́ Ńlá |
|---|---|---|---|---|---|
| Iye àwọn oníhun | Oníhun 1 | (Àwọn) Alájọṣepọ̀ 2 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ | Alájọṣepọ̀ Gbogbogbò àti Oníwọ̀nba 2 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ | Ọmọ-ẹgbẹ́ 1 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ | (Àwọn) Aṣàjọpín-èrè 1 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ |
| Ìlànà Ìbẹ̀rẹ̀ | Rọrùn 🟢 | Rọrùn 🟢 | Ṣòro Níwọ̀nba 🟡 | Ṣòro Níwọ̀nba 🟠 | Ṣòro Púpọ̀ 🔴 |
| Iye owó fún sísan/Àwọn Fọ́ọ̀mù | Òfo/ Kékeré 🟢 | Òfo/ Kékeré 🟢 | Ó Wọ́n Níwọ̀nba 🟡 | Ó Wọ́n Níwọ̀nba 🔴 | Ó Wọ́n Púpọ̀ 🔴 |
| Ìṣètò Owó-ìlú | Kò díjú púpọ̀ 🟢 | Níwọ̀nba 🟢 | Níwọ̀nba 🟢 | Níwọ̀nbá sí Lílọ́júpọ̀ 🟠 | Ó Lójúpọ Púpọ̀ 🔴 |
| Ojúṣe Gbèsè Araẹni | Gíga 🔴 | Gíga 🔴 | Ó ga fún Àwọn Alájọṣepọ Gbogbogbò 🔴 | Oníwọ̀nba 🟢 | Oníwọ̀nba 🟢 |
| Àwọn Ohun tí o Nílò tó ń lọ Lọ́wọ́ | Òfo 🟢 | Òfo 🟢 | Díẹ̀ 🟡 | Díẹ̀ 🟠 | Ó gùn púpọ̀ 🔴 |

# Alájẹṣẹ́kù Ọ̀ṣìṣẹ́

Alájẹṣẹ́kù ọ̀ṣìṣẹ́ jẹ́ àpẹẹrẹ okòwò ìṣẹ̀dá ohun tuntun nínú èyítí àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ yóò ní okòwò, tí wọn yóò sì máa ṣàkóso rẹ̀. Àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ a máa sábà dá àjọ owó sínú alájẹṣẹ́kù ní ìbẹ̀rẹ̀ láti lè di ọmọ-ẹgbẹ́, nípa bẹ́ẹ̀, wọn á sì gba iye ìwọ̀n tó tọ́ sí wọn lára èrè náà Nínú àpẹẹrẹ yìí, ọ̀ṣìṣẹ́ kọ̀ọ̀kan ní agbára ìdìbò nípa àwọn ìpinnu okòwò náà tó ṣe pàtàkì gẹ́gẹ́ bíi ìfọwọ́sí ẹ̀yáwó, ìgbaṣẹ́ṣe àti gbígba àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ tuntun.

Èyíkéyìí lára àwọn ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò tí a ṣàpèjúwe tẹ́lẹ̀rí ni ó lè da alájẹṣẹ́kù sílẹ̀, èyí tó kan àbáṣiṣẹ́pọ̀, LLC tàbí ilé-iṣẹ́ ńlá. Nígbà púpọ̀, àwọn alájẹṣẹ́kù máa ń lo ìlànà àgbékalẹ̀ LLC nítorí tí ó rọrùn, owó tí a sì fi ń dáa sílẹ̀ àti tí a fi ń múu ṣiṣẹ́ kò pọ̀ rárá sí ti ilé-iṣẹ́ ńlá, ó sì dára púpọ̀ fún ọ̀pọ̀ àwọn oníhun ju àbáṣiṣẹ́pọ̀ lọ. Alájẹṣẹ́kù LLC ní ojúṣe tó mọ níwọ̀nba fún àwọn ọmọ-ẹgbẹ́. Àwọn alájẹṣẹ́kù lè ṣèrànwọ́ láti dáàbòbo àwọn aṣíwá-láti-ìlú-iibòmíràn tí kò ní ìwé tó yẹ lábẹ́ òfin, lọ́wọ́ ìyànjẹ nípasẹ̀ jíjà wọ́n lólè iye owó iṣẹ́ wọn tàbí àwọn àṣìlò mìíràn nígbàtí wọ́n bá ń ṣiṣẹ́ ní àwọn nìkan.

Ìpínlẹ̀ New York ní Òfin Ilé-iṣẹ́ Alájẹṣẹ́kù Ọ̀ṣìṣẹ́ pàtàkì tí a ṣe pẹ̀lú ipò àti ìlànà pàtàkì tó níí ṣe pẹ́lú jíjẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́, ìpín ilé-iṣẹ́ àti pípín èrè àti àdánù. Fún àlàyé síwájú síi, jọ̀wọ́ lọ sí abala àwọn ohun àmúlò nínú ìtọ́sọ́nà yìí.



# Ìṣètumọ̀

## Ìbúra
Gbólóhùn-ọ̀rọ̀ tí a ṣàkọsílẹ̀ rẹ̀, tí a sì fọwọ́sí, tí ẹlòmíràn tí a gbà láàyè lábẹ́ òfin sì tún ṣàyẹ̀wò rẹ̀, gẹ́gẹ́ bíi ẹniti a fún ní àṣẹ láti ṣèjẹ́rìí sí àkọsílẹ̀

## Ìgbìmọ̀ Àwọn Adarí
Àkójọpọ̀ àwọn ènìyàn kọ̀ọ̀kan tí a yàn láti dúró fún àwọn aṣàjọpín-èrè nínú ilé-iṣẹ́ ńlá kan, tí wọ́n sì máà ń pèsè àbójútó lápapọ̀ fún okòwò, àti tí wọ́n tún máa ń ṣe ìpinnu
tó jẹ́ kókó.

## Oníbààrà
Ẹnìkan tàbí okòwò kan tó ń gba ìpèsè iṣẹ́ látọwọ́ agbaṣẹ́ṣe olómìnira.

## Olùdókòwò
Ẹnìkan tó máa ń ṣètò, tó sí máà ń ṣàkóso okòwò ara wọn.

## Agbanişíṣẹ́
Ẹnìkan tàbí okòwò kan tó ní ojúṣe fún owó iṣẹ́ sísan àti ipò ìríṣẹ́ṣe ẹlòmíràn.

## Nọ́mbà Ìdánimọ̀ Ẹnìkọ̀ọ̀kan Asanwó-ìlú (ITIN)
Nọ́mbà tí Ilé-iṣẹ́ Ìpawówọlé Abẹ́lé máa ń fifún àwọn ènìyàn tí kò kún ojú òṣùwọ̀n fún nọ́mbà ààbò àwùjọ ṣùgbọ́n tí wọ́n nílò láti san owó-ìlú.

## Ilé-iṣẹ́ Ìpawówọlé Abẹ́lé (IRS)
Ilé-iṣẹ́ ìjọba àpapọ̀ tó ni ojúṣe fún gbígba àwọn owó-ìlú ìjọba àpapọ̀.

## Ojúṣe
Iye ojúṣe tàbí ewu tó jẹ mọ́ òfin tàbí ọrọ̀-ajé tó níí ṣe pẹ̀lú okòwò kan.

## Ọmọ-ẹgbẹ́
Ní Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba (LLC), à ń pé àwọn oníhun ní ọmọ-ẹgbẹ́.

## Àwọn Òṣìṣẹ́ Aṣàkóso
Àwọn òṣìṣẹ́ aṣàkóso ni ó máa ń ṣàkóso iṣẹ́-ṣíṣe ọjọ́-dé-ọjọ́ ní ilé-iṣẹ́ ńlá. A`wọn ẹnití Ìgbìmọ̀ Àwọn Adarí yàn, àwọn òṣìṣẹ́ aṣàkóso tún lè jẹ́ àwọn olùdásílẹ̀/oníhun àti àwọn òṣìṣẹ́ tí a gbàsíṣẹ́ kan ńnú ilé-iṣẹ́ ńlá náà.

## Àbáṣiṣẹ́pọ̀
Ìlànà àgbékalẹ̀ okòwò nínú èyítí ẹni méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ jẹ́ oníhun okòwò náà. Nínú àbáṣiṣẹ́pọ̀ gbogbogbò, àwọn alájọṣepọ̀ a máa ṣàjọpín ojúṣe ìṣàkóso àti èrè àti àdánù okòwò náà. Nínú àbáṣiṣẹ́pọ̀ oníwọ̀nba, àwọn alájọṣepọ̀ kan máa ń ṣàkóso okòwò náà, àwọn alájọṣepọ̀ kan sì máa kàn ń náwó sínú okòwò náà ni, ṣùgbọ́n gbogbo àwọn alájọṣepọ̀ náà ní wọ́n jẹ́ oníhun okòwò náà.

## Oníhun okòwò
Oníhun okòwò náà

## Àwọn Aṣàjọpín-èrè
Aṣàjọpín-èrè jẹ́ ẹnìkan tó ti ra àwọn ìpín nínú ilé-iṣẹ́ tàbí ilé-iṣẹ́ ńlá kan. Àwọn Aṣàjọpín-èrè ni ó ni ìwọ̀n iye ìpín tó tọ́ fún iye tí wọ́n ná sínú ilé-iṣẹ́ ńlá náà.

# Àwọn Ìwé-àkọsílẹ̀ Pàtàkì

## Àkọsílẹ̀ Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba

Àkọsílẹ̀ tó ṣe àlàkalẹ̀ orúkọ Ilé-iṣẹ́ olójúṣe níwọ̀nba (LLC) náà, agbègbè rẹ̀ àti àdírẹ́ẹ̀sì tí a nílò láti ṣàgbékalẹ̀ LLC.

A ó ṣàgbékalẹ̀ LLC náà ní àsìkò tí a bá fa Àkọsílẹ̀ Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba kalẹ̀ ní ilé-iṣẹ́ ìjọba tàbí ní ìgbà mìíran lọ́jọ́ iwájú tí a mẹ́nubà nínú Àkọsílẹ̀ Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba náà, tí kò gbọ́dọ̀ pẹ́ ju ọjọ́ 60 lọ láti ọjọ́ tí a fi èyí ṣọwọ́.

*Àwọn ohun tí a ń fàkalẹ̀ ní Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀*

▶ **Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba**

## Àkọsílẹ̀ Àlàyé Ọlọ́dún-Méjì

Ní ọdọọdún méjì-méjì, NYS, LLC àti àwọn ilé-iṣẹ́ ńláńlá nílò láti fa Àkọsílẹ̀ Àlàyé Ọlọ́dún-Méjì kalẹ̀ nílé-iṣẹ́ ìjọba, kí wọ́n sì san $9 láti ṣè ìjẹ́rìísí tàbí ìmúdójúìwọn àdírẹ́ẹ̀sì.

*Àwọn ohun tí a ń fàkalẹ̀ ní Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀*

▶ **Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba** ▶ **Ilé-iṣẹ́ Ńlá**

## Àwọn òfin ìṣesí

Àkọsílẹ̀ tó sọ nípa bí ilé-iṣẹ́ ńlá náà yóò ṣe máa ṣe iṣẹ́ rẹ̀. Lára àwọn ohun tó wà nínú àlàyé yìí ni bí a ó ṣe yan àwọn adarí, bí a ó ṣe máa ṣe ìpàdé, àti àwọn ohun tó jẹ́ ẹ̀tọ́, ojúṣe àti agbára àwọn aṣàjọpín-èrè, àwọn adarí àti àwọn òṣìṣẹ́ aṣàkóso.

*A gbọ́dọ̀ tọ́jú ẹ̀dà èyí kan sínú ilé-iṣẹ́ ńlá náà.*

▶ **Ilé-iṣẹ́ Ńlá**

## Ìwé-ẹ̀rí Orúkọ ti a Yàn Láti Máa Jẹ́

Fọ́ọ̀mù tí a nílò nígbàtí orúkọ okòwò náà bá yàtọ̀ sí ti oníhun okòwò náà nìkan.

*Àwọn ohun tí à ń fàkalẹ̀ pẹ̀lú Akọ̀wé Agbègbè Náà*

▶ **Okòwò Àdánìkanni** ▶ **Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Gbogbogbò**

▶ **Ohun kan tó dádúró tó bá ń ṣiṣẹ́ lábẹ́ orúkọ tó yàtọ̀ sí orúkọ rẹ̀ lábẹ́ òfin**

## Ìwé-ẹ̀rí Ìdásílẹ̀ Ilé-iṣẹ́

Àkọsílẹ̀ tó máa ń sọ ní pàtó orúkọ àti àdírẹ́ẹ̀sì ilé-iṣẹ́ ńlá. Wíwà ilé-iṣẹ́ ńlá náà yóò bẹ̀rẹ̀ yálà ní ọjọ́ tí a fa Ìwé-ẹ̀rí Ìdásílẹ̀ Ilé-iṣẹ́ kalẹ̀ tàbí ní ọjọ́ mìíràn lọ́jọ́ iwájú (laarin ọjọ́ 90 sí ọjọ́ tí a fa ìwé-ẹ̀rí kalẹ̀) tí a sọ ní pàtó nínú Ìwé-ẹ̀rí Ìdásílẹ̀ Ilé-iṣẹ́ náà.

▶ **Ilé-iṣẹ́ Ńlá**

## Ìwé-ẹ̀rí Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba

Fọ́ọ̀mù tó sọ àwọn orúkọ àti àlàyé àwọn alájọṣepọ̀ tó ń ṣe àjọhùn àbáṣiṣẹ́pọ̀ oníwọ̀nba náà.

*Àwọn ohun tí a ń fàkalẹ̀ ní Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀*

▶ **Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba**

## Ìwé-ẹ̀rí Àtẹ̀jáde

Fọ́ọ̀mù tí a máa ń fàkalẹ̀ pẹ̀lú ìbúra láti sọ pé a ti ṣe ojúṣe tó bèèrè àtẹ̀jáde inú ìwé-ìròyìn fún bíbẹ̀rẹ̀ àbáṣiṣẹ́pọ̀ oníwọ̀nba tàbí LLC (wo ojú-ìwé 19 àti 22). A gbọ́dọ̀ fa Ìwé-ẹ̀rí Àtẹ̀jáde náà kalẹ̀ laarin ọjọ́ 120 lẹ̀yín tí a fa Ìwé-ẹ̀rí Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba tàbí Àkọsílẹ̀ Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba kalẹ̀ tán.

*Àwọn ohun tí a ń fàkalẹ̀ ní Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀*

▶ **Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba**

▶ **Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba**

## I-9, fọ́ọ̀mù Ìṣèjẹ́rìísí Kíkún Ojú Òṣùwọ̀n Láti Ṣiṣẹ́

Fọ́ọ̀mù tí a nílò fún gbogbo òṣìṣẹ́ tí a gbàsíṣẹ́ kí wọ́n báa lè ṣèjẹ́rìí pé àwọn lè ṣiṣẹ́ lábẹ́ òfin ní United States. Agbanisíṣẹ́ rẹ gbọ́dọ̀ gba Fọ́ọ̀mù I-9, kí ó sì jẹ́ kí ó wà nítòsí fún àyẹ̀wò àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba U.S. tí a fún láṣẹ.

## Àjọhùn Iṣẹ́-ṣíṣe

A máa sọ àwọn ẹ̀tọ́, agbára, àwọn ohun ìnífẹ̀ẹ́sí, àwọn ohun àìgbọdọ̀ṣe tàbí ojúṣe àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ rẹ̀, àwọn òṣìṣẹ́ àti àwọn aṣojú rẹ̀. A lè ṣe Àjọhùn Iṣẹ́-ṣíṣe náà ṣáájú tàbí laarin ọjọ́ 90 lẹ́yìn ti a ti fi Àkọsílẹ̀ Àgbékalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba náà kalẹ̀ sọ́dọ̀ àwọn aláṣẹ.

*A gbọ́dọ̀ tọ́jú ẹ̀dà èyí kan sínú LLC náà*

▶ **Ilé-iṣẹ́ Olójúṣe Níwọ̀nba**

## Àwọn àjọhùn àbáṣiṣẹ́pọ̀

A dáa lábàà fún àbáṣiṣẹ́pọ̀ gbogbogbò, bẹ́ẹ̀ sì ni àbáṣiṣẹ́pọ̀ oníwọ̀nba nílò rẹ̀, ó máa ń mú kí àwọn ètò, ẹ̀tọ́ àti ojúṣe laarin àwọn alájọṣepọ̀ okòwò lè fẹsẹ̀múlẹ̀, kí ẹ̀rí sì wà fún wọn.

▶ **Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Gbogbogbò**

▶ **Àbáṣiṣẹ́pọ̀ Oníwọ̀nba**

# Àwọn Ohun Àmúlò

## Àwọn Ilé-iṣẹ́ Aṣojú Ìjọba Ìpínlẹ̀ NY:

### Ẹ̀ka Ìpínlẹ̀, Ìpín-ẹ̀ka Àwọn Ilé-iṣẹ́ Ńláńlá, Àwọn Àkọpamọ́ Ìpínlẹ̀, àti UCC

www.dos.ny.gov/corps/
Àlàyé nípa àti àwọn àpẹẹrẹ fọ́ọ̀mù àti àwọn àkọsílẹ̀ lábẹ́ òfin mìíràn tí a lè nílò láti ṣí tàbí láti fẹjú okòwò ní Ìpínlẹ̀ New York.

### Ìdàgbàsókè Ìpínlẹ̀ Ìjọba, Ètò Ìrànlọ́wọ́ Olùdókòwò

esd.ny.gov/entrepreneurial-assistance-program
Ètò Ìrànlọ́wọ́ Olùdókòwò (EAP) ṣe ìdásílẹ̀ ibùdó EAP ní àwọn àwùjọ agbègbè káàkiri Ìpínlẹ̀ New York láti pèsè ìtọ́sọ́nà, ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn iṣẹ́ ìrànlọ́wọ́ àti àtìlẹ́yìn nípa àwọn ohun tó nílò ìmòye pàtàkì fún àwọn ènìyàn tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ okòwò ti ara wọn tàbí tí wọ́n nífẹ̀ẹ́sí bíbẹ̀rẹ̀ okòwò.

### Ọ́fíìsì Àwọn Ará Amẹ́ríkà Tuntun (ONA)

1-800-566-7636
www.newamericans.ny.gov/business
Ọ́fíìsì Àwọn Ará Amẹ́ríkà Tuntun ní àwọn ibùdó àǹfàní 27 káàkiri Ìpìnlẹ̀ New York láti pèsè àwọn ohun àmúlò ìkọ́ni àti ti ọrọ̀-ajé fún àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn, èyí tó kan ìrànlọ́wọ́ fún àwọn okòwò kékèké.

### Ibùdó Ìdàgbàsókè Okòwò Kékèké (SBDC)

1-800-732-7232
www.nysbdc.org/
Nípasẹ̀ àsopọ̀ àwọn ibùdó ẹ̀kùn 24, Ibùdó Ìdàgbàsókè Okòwò Kékèké ní Ìpínlẹ̀ New York (NYS SBDC) máa ń pèsè ìgbaninímọ̀ràn àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nípa okòwò, èyí tó jẹ́ oníwọn gíga, lọ́fẹ̀ẹ́ tàbí ní owó pọ́ọ́kú, fún àwọn ará New York tó fẹ́ bẹ̀rẹ̀ okòwò tàbí tó fẹ́ mú ìtẹ̀síwájú bá ìṣesí okòwò tó ti wà tẹ́lẹ̀rí, lọ́fẹ̀ẹ́.

## Àwọn Ilé-iṣẹ́ Aṣojú Ìjọba NYC:

### Ẹ̀ka tó ń rísí Ọ̀ràn Aṣàmúlò-ìkẹyìn, Ọ́fíìsì Ìrónilágbára fún Ọrọ̀-ajé

www.nyc.gov/site/dca/partners/financial-empowerment.page
Ẹ̀kọ́ àti ìgbaninímọ̀ràn nípa ọrọ̀-ajé pẹ̀lú èròǹgbà ìrónilágbára àti ìdáàbòbo àwọn ará New Yorkk tó ń pa owó kékèké wọlé, tí wọ́n sì fẹ́ mú àwọn ohun-ìní wọn gbèrú síi, kí wọ́n sì lo àwọn ohun àmúlò ara wọn tó jẹ mọ́ owó lọ́nà tó dára jùlọ. Lára èyí ni àlàyé nípa ìfowópamọ́ lọ́nà tó ní ààbò, tó sì rọrùn, àti láti ráàyèsí àwọn ẹ̀yáwó owó-ìlú tó lè mú owó tó ń wọlé pọ̀ síi.

### Àwọn Ìpèsè Iṣẹ́ Okòwò Kékèké (SBS)

https://www1.nyc.gov/nycbusiness/
Ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́, ìdánilẹ́kọ̀ọ́, ìgbaninímọ̀ràn, àti ìrànlọ́wọ́ fún àwọn olùdókòwò tó nífẹ̀ẹ́ láti ṣèdásílẹ̀, ṣàkóso, tàbí ṣe ìmúdàgbàsókè okòwò ní Ìlú New York.

### Ìgbésẹ̀ Okòwò Aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn ti SBS

www1.nyc.gov/nycbusiness/article/immigrant-business-initiative
SBS ń pèsè ẹ̀kọ́ nípa okòwò, ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́, ìrànlọ́wọ́ owó, ìpèsè iṣẹ́ ìmòfin lọ́fẹ̀ẹ́, àti jù bẹ́ẹ̀ lọ ní àwọn oríṣiríṣi èdè káàkiri Ìlú New York láì sanwó.

## Àwọn Àjọ NYC:

### Ilé-ìkàwé Gbogbogbò ní Brooklyn, Àwọn Ìpèsè Iṣẹ́ Okòwò Kékèké àti ti Olùdókòwò

www.bklynlibrary.org/business/small-business
Ọ̀pọ̀ àwọn ibùdó káàkiri Àwọn Ohun Àmúlò Brooklyn, ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́, kíláàsì, àti ìrànlọ́wọ́ ojúkojú ní èdè Gẹ̀ẹ́sì, Spanish, Russia àti Kreyol nípa bíbẹ̀rẹ̀, mímúṣiṣẹ́, àti mímúgbèrú okòwò.

### Business Outreach Center Network (BOCNET)

www.bocnet.org
Àjọ ìdàgbàsókè okòwò-bíńtí àti kékèké tó ń pèsè àwọn iṣẹ́ àkànṣe okòwò ní Bronx, Brooklyn, Manhattan, Queens, Staten Island fún àwọn àwùjọ tí a kò kìí sábà rànlọ́wọ́, èyí tó kan àwọn ẹ̀yáwó fún okòwò kékèké, ìṣètọ́jú ọmọdé lábẹ́lé, àwọn ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́ 'Business American-Style', àti Àkànṣe Iṣẹ́ Okòwò-Bíńtí Asáàsálà.

### Àwọn Iṣẹ́ CAMBA fún Okòwò Kékèké

718-287-2600
www.camba.org
Ìfọ̀rànlọ̀ni olójúkojú, àkójọ ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́ fún okòwò kékèké, àmọ̀ràn nípa okòwò, àsonipọ̀ pẹ̀lú àwọn alájọṣepọ̀ ìdàgbàsókè okòwò kékèké mìíràn, àti ẹ̀yáwó fún okòwò.

### Àkanṣe Iṣẹ́ Ìdàgbàsókè Àwùjọ Ènìyàn Ẹgbẹ́ Ìrànwọ́ Ìmòfin

212-426-3000
www.legalaidnyc.org/civil-practice-pro-bono-projects
Ń ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn alágbàwí àti àwùjọ tó kún ojú òṣùwọ̀n fún irú ìpèsè bẹ́ẹ̀ káàkiri agbègbè ìpàṣẹ́ máràárùn. Àwọn àkórí-ọ̀rọ̀ jẹ́ bíbẹ̀rẹ̀ okòwò kékèké, bíbuwọ́lu àjọhùn ìyálélò, dídáàbòbo okòwò àti àwọn ohun-ìní araẹni. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wà ní èdè Gẹ̀ẹ́sì àti Spanish.

# Àwọn Ohun Àmúlò

### Ibùdó fún Ìmọ̀ Ẹ̀kọ́ Ìlú-ńlá (CUP)

www.welcometocup.org
Àtẹ̀jáde àwọn ìwé ìmọ̀ràn pélébé láti mú àwọn ìpinnu àti ìlànà tó lọ́júpọ̀ lọ́júùtú, èyí tó kan Ìtọ́sọ́nà sí Àwọn Alájẹṣẹ́kù Òṣìṣẹ́ ní NYC.

### Ẹgbẹ́ Heberu Ayánilọ́wọ́ Ọ̀fẹ́

www.hfls.org/loan-programs/microenterprise/
Àwọn ẹ̀yáwó okòwò-bíńtí tí kò ní àsanlé fún àwọn olùgbé Ìlú New York, Long Island, àti Westchester, tó ń pawó tó kéré díẹ̀ tàbí tó mọ níwọ̀nba wọlé, láti lè bẹ̀rẹ̀ okòwò tàbí múu ga síi.

### Neighborhood Entrepreneur Law Project, NYC Bar Justice Center

212-382-6633 (àkọ́kọ́)
212-626-7383 (Ìpé ìmọ̀ràn òfin ọ̀fẹ́)
nelp@nycbar.org
Ìpèsè ìmọ̀ràn nípa òfin fún àwọn olùdókòwò-bíńtí tó ń pawó tó kéré tàbí tó mọ níwọ̀nba wọlé láti bẹ̀rẹ̀ okòwò, èyí tó kan àwọn ọ̀rọ̀ owó-ìlú, ìgbaṣẹ̀ṣe àti àjọhùn, ìdúnàdúrà ìyálélò tó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀-ajé, ẹ̀tọ́-ẹ̀dà, ààmì-ìtajà, àti àṣẹ ìtajà.

### Renaissance Economic Development Corporation

www.renaissance-ny.org
Àgbékalẹ̀ Ọrọ̀-ajé Ìdàgbàsókè Àwùjọ tí a yàsọ́tọ̀ láti ṣàtúndá àwọn aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn, àwọn àwujọ tó ń pawó tó kéré tàbí tó mọ níwọ̀nba wọlé ní NYC nípa pípèsè ẹ̀yáwó okòwò tí àsanlé rẹ̀ kéré, àti àwọn ètò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn olùdókòwò.

### Àwọn Olùfarasín fún Ìpèsè Ìmọ̀ràn Òfin

347-521-5729
www.volsprobono.org/projects/microenterprise-project
Ń ran àwọn oníhun okòwò kékèké àti àwọn olùdókòwò-bíńtí lọ́wọ́ láti ráàyèsí àwọn ìpèsè ìmọ̀ràn òfin ọ̀fẹ́ tó jẹ́ oníwọ̀n gíga, látọwọ́ àwọn òṣìṣẹ́ tó ya ara wọn sọ́tọ̀ àti àwọn àjọ àwọn amòfin tó ń pèsè iṣẹ́ lọ́fẹ̀ẹ́.

## Àwọn Ohun Àmúlò Alájẹṣẹ́kù NYC:

### Green Workers Coop

www.greenworker.coop
Ń pèsè ìdánilẹ́kọ̀ọ́ olóṣù 5 pẹ̀lú ètò ìṣàtìlẹ́yìn tó ń ran ẹgbẹ́ àwọn olùdókòwò tó ń gbìyànjú lọ́wọ́ láti mú ìdàgbàsókè bá àwọn okòwò tó jẹ́ ti àwọn òṣìṣẹ́ aláwọ̀-ewé, wọ́n sì máa ń lo àpapọ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́, ìkọ́ni àti ìpèsè ìmọ̀ ẹ̀rọ.

### Àsopọ̀ Àwọn Aláj̣ẹṣẹ́kù Òṣìṣẹ́ ní Ìlú New York (NYC NOWC)

212-390-8178 (ìpè tààrà)
www.nycworker.coop
Ìdàgbàsókè Olùdarí, ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àkójọ ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́, àtìlẹ́yìn okòwò, àti àtìlẹ́yìn nípa àwọn ohun tó nílò ìmòye pàtàkì nípa àwọn aláj̣ẹṣẹ́kù òṣìṣẹ́ àti mímọ̀ọ́ṣe okòwò aláj̣ẹṣẹ́kù.

### Àkànṣe Iṣẹ́ Ìdájọ́ Àwọn Òṣìṣẹ́ - Make The Road New York

347-889-6347
www.workersjustice.org
Àjọ ẹ̀tọ́ aṣíwá-láti-ìlú-ibòmíràn laarin àwọn ohun mìíràn ń ṣiṣẹ́ fún ìṣẹ̀dá àwọn iṣẹ́ tó lè pé títí nípasẹ̀ ìmúdàgbàsókè, àtìlẹ́yìn àti ìgbéga àwọn aláj̣ẹṣẹ́kù tó jẹ́ ti òṣìṣẹ́.

## Àwọn Irinṣẹ́ Orí Ayélujára:

### New York Business Express

www.businessexpress.ny.gov
Ń ṣèrànwọ́ láti pèsè ìtọ́sọ́nà fún ọ nípa àwọn ohun tí o nílò fún okòwò àti iṣẹ́ rẹ. Kọ ohun tó yẹ sínú ìwé-ìbéèrè, Arannilọ́wọ́ Okòwo yóò sì pèsè àkójọ ohun gbogbo tí o nílò láti bẹ̀rẹ̀ okòwò fún ọ.

### Ààyè Ayélujára Okòwò NYC

www1.nyc.gov/nycbusiness

**Ìwé-ìbéèrè Ẹlẹ́sẹẹsẹ**
Kọ ohun tó yẹ lẹ́sẹẹsẹ sínú ìwé-ìbéèrè kan, kí o sì gba àkójọ àkànṣe àwọn ìwé-àṣẹ àti ìgbaniláàyè ti ìlú, ìpínlẹ̀ àti ti ìjọba àpapọ̀ tí o lè nílò láti bẹ̀rẹ̀ àti láti mú okòwò rẹ ṣiṣẹ́, èyí tó dá lórí irú iṣẹ́ tí ìwọ ń ṣe.

**Aṣèṣirò Ẹ̀wúrí**
Kọ ohun tó yẹ sínú ìwé-ìbéèrè kan, kí o sì gba àkójọ àwọn oríṣiríṣi ẹ̀wúrí ìjọba àti ẹ̀yáwó owó-ìlú tó wà, ti okòwò rẹ lè kún ojú òṣùwọ̀n fún.